# ỌRỌ NIPA IDAJỌ IDAN ATI .ṢÍṢE YẸ̀MÍWÒ

Ti o jẹ ti olumọ àgbà ‘Abdul ‘Azeez ibn ‘Abdullāh ibn Bāz.

ح **جمعية الدعوة و الارشاد وتوعية الجاليات بالربوة ، ١٤٤٥هـ**

بن باز، عبد العزيز

حكم السحر والكهانة - يوربا. / عبد العزيز بن باز - ط.١ -.

الرياض، ١٤٤٥هـ

٨٤ ص ؛ ١٤ × ٢١ سم

ردمك: ٥-٩٣-٨٤١٧-٦٠٣-٩٧٨

١٤٤٥ / ٢٠٨٥٤

شركاء التنفيذ:

المحتوى الإسلامي رواد الترجمة جمعية الربوة دار الإسلام

يتاح طباعة هذا الإصدار ونشره بأي وسيلة مع الالتزام بالإشارة إلى المصدر وعدم التغيير في النص.

Telephone: +966114454900
ceo@rabwah.sa
P.O.BOX: 29465
RIYADH: 11557
www.islamhouse.com

Ni Orukọ Allah, Ajọkẹ-aye, Aṣakẹ ọrun

## Ọrọ isaaju

Gbogbo ẹyin ti Ọlọhun ni, ikẹ ati ọla ki o lọ máa bá ojiṣẹ Ọlọhun ati awọn araale rẹ ati awọn saabe rẹ, ati ẹnití o ba mọ ọna pẹlu ilana rẹ, lẹyin naa:

Dájúdájú idan jẹ ọkan ninu awọn ìyá ẹ̀ṣẹ̀, ati ninu awọn nkan meje ti máa ń kó iparun bá ni eléyìí tí Ọlọhun ati Ojiṣẹ Rẹ - kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- pàṣẹ jijina sí i. Idán pipa ti tan kálẹ̀ ni awọn àsìkò yìí tí o si tun han pẹlu awọn aworan orisirisi, ati awọn ọna ti o pọ. Ni igba mii a máa ṣẹlẹ lórúko eré ati àwàdà ninu awọn fíìmù ti maa n mu inú ẹni dùn, àti pé ni ìgbà miran a máa ṣẹlẹ lórúkọ irayesa ati iṣẹ́ ìyanu. Nigba miran a sì máa ṣẹlẹ lórúkọ rúkíyà ti o ba òfin Ọlọhun mu, nigba miran a máa ṣẹlẹ ní orúkọ oogun ibilẹ, ati ṣíṣe ìwòsàn pẹlu ewe ati egbo, titi dori awọn ti o yatọ si iyẹn ninu awọn aworan ati ojupọna

ti idan máa n gba hàn, ti o si pamọ fun awọn alaimọkan ati awọn ti ko sì amọdaju lọdọ wọn ninu ẹsin.

Fun tìtorí nǹkan ti o n bẹ ninu tira mufuti gbogboogbo fún orilẹ-ede Saudi Arabia ati olori iparapọ awọn àgbà olumọ ati didari ìwádìí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ ati ṣíṣe idajọ ẹsin, olumọ àgbà ‘Abdul ‘Azeez ibn ‘Abdullāhi ibn Bāz - ki Ọlọhun kẹ ẹ- nipa idan ati sisọ ni lara kuro nibẹ, ati idajọ lilọ ba yẹmiwo, pẹlu ọna ti o rọrun, pẹlu ẹri ti o ba sharia mu láti inú Alikuraani ati Sunna Anabi ti o mọ. Nitori naa, ẹkun ti o n ri sí àwọn àlámọ̀rí ẹsin ati awọn ẹbun ti a fi sọrí awọn kan ati ipepe ati itọnisọna, wọn ri i wipe ki wọn o gbe tira yii sita ki wọn sì tẹ ẹ jade.

Wọn ka tira alfa agba yii nipa alaye idan ati imaa lọ bá àwọn yẹmiwo ati opidan kun ipin kan ninu awọn igbiyanju rẹ ti o ni alubarika, ati ilọwọsi rẹ ti o pọ ti ko ni opin nibi pipe awọn eeyan lọ síbi dáadáa, ati nini agbọye ẹsin, ati ṣíṣe àlàyé àwọn idajọ, ati sisọ ni lara kuro nibi awọn nkan ti ko dára, ati titaniji lori rẹ, ati ṣíṣe iṣiti fún

àwọn Musulumi, ati pipe wọn lọ síbi didirọ mọ tira Ọlọhun Alapọnle ati Sunna Anabi Rẹ, ẹnití a fọ mọ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - àti rírìn lori ilana awọn aṣiwaju rere, ati tita nkan ti o ba yatọ sí ìyẹn danu ninu awọn ero ati ilana ati adisọkan aburú.

Eleyii ni oun ti ilu alalubarika yii wà lórí rẹ ati awọn adari rẹ ti wọn jẹ olùmọ̀nà, kí Ọlọhun fi ẹsẹ rẹ rinlẹ lori ìyẹn, kí O sì tun ṣe e ni irọrun fún un àwọn òkùnfà iranlọwọ ati ìfiṣe kongẹ ati ikunlọwọ, kí O sí tun san olumọ àgbà ti o kọ tira yii ni ẹsan dáadáa, kí O si tun fun un ni laada ti o pọ.

A wa n béèrè lọwọ Ọlọhun ki o ṣe ẹnití o ba ka a ni anfaani tabi ẹnití o ba gbọ ọ tabi ẹnití o ba yẹ ẹ wo, kí O si tun fi gbogbo wa m'ọna lapapọ lati dirọ mọ Kuraani ati Sunna, kí O si tun gbe wa jina sí àwọn erokero Shaytān ati awọn oju-ọna rẹ ati awọn ilana rẹ, Oun ni Alamojuto iyẹn ati Olukapa rẹ, atipe Ọlọhun ni Olufini m'ọna lọ sí ọna ti o tọ, kí Ọlọhun ṣe ikẹ ati ọla fún Anabi wa

Muhammad, ati awọn ara ile rẹ ti wọn tẹle e ati awọn Saabe rẹ lapapọ.

‘Abdullāhi bn ‘Abdul Muhsin at-Turkiy.

Mínísítà ti n ri sí àwọn àlámọ̀rí ẹsin ati awọn ẹbun ti a fi sọri awọn kan ati ipepe ati ìtọ́nisọ́nà.

## Ìdájọ́ idan ati ṣíṣe yẹmiwo, ati nkan ti o rọ mọ ..ọn [1]

Gbogbo ẹyin ti Ọlọhun ni ni Oun nikan ṣoṣo, ikẹ ati ọla ki o lọ máa bá ẹnití ko si Anabi kankan lẹyin rẹ, lẹyin naa

Torí pipọ awọn ti n pa ọwọ da ni àsìkò yii ninu awọn ti n pé apemọra imọ iṣegun ti wọn sì n ṣe ìwòsàn lati ipasẹ idan tabi ṣíṣe yẹmiwo, ati fifọnka wọn ni awọn ilu kan, ati bi wọn ṣe n lo àǹfààní awọn ti oponu ninu awọn èèyàn ni awọn ti aimọkan ti b'ori wọn, mo ri pe ninu ṣiṣe iṣiti torí Ọlọhun ati fún àwọn ẹrù Rẹ ni ki n ṣe àlàyé ewu nlá ti n bẹ nibẹ lori Isilaamu ati awọn Musulumi látàrí nǹkan ti n bẹ nibẹ bii imaa so ọkan pọ mọ nǹkan ti o yatọ sí Ọlọhun ti ọla Rẹ ga, ati yiyapa aṣẹ Rẹ ati aṣẹ ojiṣẹ Rẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a).

Nitori naa mo n sọ l’ẹniti n wa ikunlọwọ Ọlọhun ti ọla Rẹ ga pe o tọ ki a fi oògùn ṣe iwosan pẹlu ipanupọ awọn onimimọ, ati pe Musulumi le lọ sí ọdọ dókítà awọn àìsàn

tí inu ati ti iṣẹ abẹ, ati awọn àìsàn iṣan tabi nkan ti o jọ ìyẹn; lati sọ irú àìsàn ti n ṣe e fún un, kí o si tun ṣe ìwòsàn fún ùn pẹlu nkan ti o ba a mu ninu oogun ti o lẹtọọ labẹ ofin ni ibamu sí nkan ti o mọ ninu ìmọ̀ iṣegun; nitoripe ìyẹn n bẹ ninu ṣiṣe àmúlò awọn òkùnfà ti àṣà ti ko sì tako igbarale Ọlọhun, àti pé Ọlọhun ti mimọ n bẹ fún Un ti ọla Rẹ sì tún ga ti sọ àìsàn kalẹ ti O si tun sọ iwosan rẹ kalẹ pẹlu rẹ, ẹnití o mọ ọn mọ ọn ẹnití o ko si mọ ọn ko mọ ọn, amọ Ọba tí mimọ n bẹ fún Un ko fi ìwòsàn àwọn ẹrú Rẹ síbi nkan ti O ṣe ni eewọ fún wọn. Nitori naa ko ni ẹtọ fún aláìsàn ki o lọ sí ọdọ àwọn yẹmiwo ti wọn máa n pe apemọra ìmọ̀ nǹkan ti o pamọ lati mọ àìsàn rẹ ni ọdọ wọn, gẹ́gẹ́ bi ko ṣe ni ẹtọ fún un kí o gba wọn ni òdodo nibi nkan ti wọn n fún un ni ìró nipa rẹ; nítorí pé wọn máa n sọrọ tí kò dá wọn lójú, tabi ki wọn máa pe alujannu lati wa iranwọ pẹlu wọn lori nkan ti wọn n fẹ, ìdájọ́ wọn ni ijẹ keferi ati anu ti wọn ba pe apemọra ìmọ̀ kọ̀kọ̀, o ti wa ninu Sọhīhul Muslim pe dajudaju Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pe: Ẹnití o ba wa ba yẹmiwo, kan ti

o wa bi i leere nipa nkankan, wọn ko nii gba irun rẹ fún ogoji ọjọ. Láti ọdọ Abu Hurayrah - ki Ọlọhun yọnu sí i - lati ọdọ Anabi - kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - o sọ pe : Ẹnití o ba wa ba yẹmiwo kan, ti o si gba a l'ododo pẹlu nkan ti o n sọ, ẹni naa ti ṣe aigbagbọ pẹlu nǹkan ti wọn sọkalẹ fún Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a). Abu Dāud ni o gba a wa, ti awọn oni tira sunna mẹrẹrin sì gbé e jáde, ti Al-Hākim sì ni o ni àlàáfíà lati ọdọ Anabi - kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - pẹlu gbólóhùn : Ẹnití o ba wa ba yẹmiwo kan tabi adadigba kan, ti o wa gba a l'ododo pẹlu nkan ti o n sọ, o ti ṣe aigbagbọ pẹlu nkan ti wọn sọkalẹ fún Muhammad (kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a). Lati ọdọ ‘Imrān ọmọ Husọen - ki Ọlọhun yọnu sí i- o sọ pe : Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - sọ pe : Ko si ní ara wa ẹnití o ba fi ẹyẹ wo iṣẹ́ tabi ti wọn fi ẹyẹ wo iṣẹ fun un, tabi ti o ba yẹ iṣẹ́ wo, tabi wọn wo iṣẹ́ fun un, tabi ẹnití o ba pa idán abi wọn pa idan fún un, ẹnití o ba lọ ba yẹmiwo kan, ti o wa gba nǹkan ti o n sọ gbọ, o ti ṣe aigbagbọ pẹlu nǹkan ti wọn sọkalẹ fún

Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a). Al-Bazzār ni o gba a wa pẹlu isnaadu tí o daa. O wa ninu awọn hadīth abiyi yii kikọ kuro nibi imaa lọ bá àwọn tí nwo iṣẹ ati awọn adadigba ati awọn opidan ati awọn ti wọn jọ wọn, ati imaa bi wọn leere ati imaa gba wọn ni òdodo, ti adehun iya sí wa lori ìyẹn. Nitori naa nkan ti o jẹ dandan lori awọn alaṣẹ ati awọn alamojuto àlámọ̀rí ẹsin ati awọn tó yàtọ̀ sí wọn nínú àwọn ti wọn ní ikapa ati agbara kikọ iwa ibajẹ láti lọ ba àwọn adagbigba ati awọn ti n yẹ iṣẹ wo ati awọn tó jọ wọn, ati kikọ fún ẹnití ba n ṣe nkankan ninu ìyẹn ninu awọn ọja ati ibi tí o yatọ sí i, ati kikọ fún wọn ni kikọ ti o le, ati kikọ fún àwọn ti wọn n wa ba wọn. Ko sì lẹtọọ ki o gba ẹtan pẹlu ododo wọn nibi awọn àlámọ̀rí kan, ko si tun gbọdọ gba itanjẹ pẹlu ọpọ àwọn tí wọn nlọ ba wọn nínú àwọn èèyàn nítorí pé alaimọkan ni awọn yẹn, ko sì lẹtọọ ki awọn eeyan o gba ẹtan pẹlu wọn; nitoripe dajudaju ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - ti kọ kuro nibi imaa lọ bá wọn ati imaa bi wọn leere ati imaa gbà wọn ni òdodo latari nkan ti n bẹ níbẹ̀ ni ibajẹ

ti o tobi ati ewu nla ati àtúnbọ̀tán aburú àti nítorí pé àwọn yẹn jẹ opurọ ati obilẹjẹ. Gẹgẹbi o ṣe wa ninu awọn Hadiisi yii ẹri lori jijẹ keferi adagbigba ati opidan nitoripe dajudaju awọn mejeeji n pé apemọra imọ kọkọ ti ìyẹn sì jẹ iṣe-keferi, ati pe dajudaju awọn mejeeji o le dé ibi erongba wọn ayafi lati ipasẹ lilo alujannu ati sisin wọn lẹyin Ọlọhun Allāhu, ti ìyẹn sì jẹ iṣe keferi sí Ọlọhun ati imu orogun pẹlu Rẹ, mimọ n bẹ fún Un, àti pé ẹnití o ba gba wọn ni ododo nibi apemọra imọ kọkọ wọn, oun naa yíò da gẹgẹ bii wọn, ẹnití o ba gba awọn àlámọ̀rí yìí lati ọdọ awọn ti n ṣe e, ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - ti bọpa-bọsẹ kuro lọdọ wọn. Ko lẹtọọ fún Musulumi ki o juwọ silẹ fún nǹkan ti wọn pe ní ìwòsàn gẹgẹbi wọn ṣe máa ṣe awọn talasimu (awọn ọrọ to ruju tí wọn máa n kọ sinu tira) ni ọ̀ṣọ́ tabi dída òjé sinu abọ (lati fi tu asasi) ati eyiti o jọ ìyẹn ninu awọn ohun asán ti wọn nṣe, nitori naa dajudaju eléyìí wà nínú idagbigba (wiwo irawọ) ati dida ọrọ ru mọ awọn eeyan lójú, ẹnití o ba yọnu si iyẹn ti ran wọn lọwọ lórí ibajẹ wọn ati iṣe-

keferi wọn. Ko sì tun ni ẹtọ bakanna fún ẹnikẹni nínú Musulumi ki o lọ bá wọn lati bí wọn leere nipa ẹnití ọmọ rẹ tabi alasunmọ rẹ máa fẹ tabi nipa ohun ti yíò wa laarin tọkọtaya ati ẹbi awọn mejeeji ni ifẹ ati pípé àdéhùn tabi ọta ṣiṣe.

ati opinya ati nkan ti o jọ ìyẹn; torí pé dajudaju eléyìí wa ninu kọkọ èyí tí o ṣe wipe kò sí ẹnití o mọ ọn àyàfi Ọlọhun, mimọ n bẹ fún Un, ti ọla Rẹ sì tún ga.

Idan wa ninu awọn nǹkan eewọ ti máa n sọ ẹni di keferi, gẹgẹbi Ọlọhun ti O biyi ti O gbọnngbọn ṣe sọ nípa àwọn Malaika méjì nínú Sūratul Baqorah: “Wọn kò sì níí kọ́ ẹnikẹ́ni àyàfi kí wọ́n wí pé: "Àdánwò ni wá. Nítorí náà, má di kèfèrí.

﴿وَٱتَّبَعُواْ مَا تَتۡلُواْ ٱلشَّيَٰطِينُ عَلَىٰ مُلۡكِ سُلَيۡمَٰنَۖ وَمَا كَفَرَ سُلَيۡمَٰنُ وَلَٰكِنَّ
ٱلشَّيَٰطِينَ كَفَرُواْ يُعَلِّمُونَ ٱلنَّاسَ ٱلسِّحۡرَ وَمَآ أُنزِلَ عَلَى ٱلۡمَلَكَيۡنِ بِبَابِلَ هَٰرُوتَ
وَمَٰرُوتَۚ وَمَا يُعَلِّمَانِ مِنۡ أَحَدٍ حَتَّىٰ يَقُولَآ إِنَّمَا نَحۡنُ فِتۡنَةٞ فَلَا تَكۡفُرۡۖ فَيَتَعَلَّمُونَ
مِنۡهُمَا مَا يُفَرِّقُونَ بِهِۦ بَيۡنَ ٱلۡمَرۡءِ وَزَوۡجِهِۦۚ وَمَا هُم بِضَآرِّينَ بِهِۦ مِنۡ أَحَدٍ إِلَّا
بِإِذۡنِ ٱللَّهِۚ وَيَتَعَلَّمُونَ مَا يَضُرُّهُمۡ وَلَا يَنفَعُهُمۡۚ وَلَقَدۡ عَلِمُواْ لَمَنِ ٱشۡتَرَىٰهُ مَا لَهُۥ فِي
ٱلۡأٓخِرَةِ مِنۡ خَلَٰقٖۚ وَلَبِئۡسَ مَا شَرَوۡاْ بِهِۦٓ أَنفُسَهُمۡۚ لَوۡ كَانُواْ يَعۡلَمُونَ ١٠٢﴾ [البقرة:
102]

" **Wọ́n sì ń kẹ́kọ̀ọ́ ohun tí wọn yóò fi ṣòpínyà láàrin ọmọnìyàn àti ẹnì kejì rẹ̀ lọ́dọ̀ àwọn àlùjànnú méjèèjì**. – **Wọn kò sì lè kó ìnira bá ẹnikẹ́ni àyàfi pẹ̀lú ìyọ̀nda Allāhu**. – **Wọ́n ń kẹ́kọ̀ọ́ ohun tí ó máa kó ìnira bá wọn**, **tí kò sì níí ṣe wọ́n ní ànfààní**. **Wọ́n kúkú ti mọ̀ pé ẹnikẹ́ni tí ó bá ra idán, kò níí sí ìpín rere kan fún un ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn**. **Aburú sì ni ohun tí wọ́n rà fún ẹ̀mí ara wọn tí ó bá jẹ́ pé wọ́n mọ̀**."[1]

Nitori náà àwọn aayah alapọn-ọnle yii tọka wipe dajudaju idan jẹ iṣe aigbagbọ, àti pé awọn opidan máa n ṣe opinya laarin ọmọnìyàn ati ìyàwó rẹ, o tun tọka si wipe dajudaju idan o lee lapa fúnra rẹ ni ti anfaani tabi inira, bi ko ṣe wipe yíò máa lapa pẹlu iyọnda Ọlọhun ni ti akọsilẹ; torí pé dajudaju Ọlọhun ti mimọ n bẹ fún Un ti ọla Rẹ sì tún ga ni Ẹnití O da dáadáa ati aburú, àti pé inira naa ti pọ ti wahala naa sì lekoko pẹlu awọn opurọ yìí awọn ti wọn jogún awọn imọ yìí lati ọdọ awọn ọsẹbọ, ti wọn sì dà a ru mọ awọn ti làákàyè wọn lẹ loju, nitori naa ọdọ Ọlọhun ni a ti wa ọdọ Rẹ náà ni a sì maa padà sí, àti pé Allāhu tó fún wa, Ó sì dára ni Alamojuto. Gẹgẹbi aaya alapọn-ọnle naa ṣe tọka si wipe dajudaju awọn ti wọn n kọ idan, nǹkan ti yíò ko inira ba wọn ni wọn n kọ ti ko sì nii ṣe wọn ni anfaani, àti pé dajudaju ko sì ìpín kankan fún wọn ní ọdọ Ọlọhun, eléyìí jẹ adehun iya ti o tobi ti o tọka sí lile ofo wọn ni ayé àti ní ọjọ ìkẹhìn, àti pé dajudaju wọn ti ta ẹmi wọn ni owo kekere, fún ìdí èyí Ọlọhun ti

mimọ n bẹ fún Un ti ọla Rẹ sì tún ga bu wọn lori ìyẹn pẹlu gbólóhùn Rẹ ti o sọ pe:

﴿وَلَبِئۡسَ مَا شَرَوۡاْ بِهِۦٓ أَنفُسَهُمۡۚ لَوۡ كَانُواْ يَعۡلَمُونَ١٠٢﴾ [البقرة: 102]

“**Aburú sì ni ohun tí wọ́n rà fún ẹ̀mí ara wọn tí ó bá jẹ́ pé wọ́n mọ̀.**[2]”

Ash-Shiraa’u nibi yii, ìtumọ̀ rẹ ni Tita.A ń béèrè lọwọ Ọlọhun alaafia ati ọla kuro nibi aburu awọn opidan ati awọn adagbigba ati àwọn onișẹ ibi yoku, gẹgẹbi a șe n beere lọwọ Rẹ - mimọ ni ti Rẹ - ki O la awọn Musulumi kuro nibi aburu wọn, kí O tun fi awọn adari awọn Musulumi șe kongẹ lọ sibi șișọra fún wọn, àti lílo ìdájọ́ Ọlọhun lori wọn titi ti awọn ẹrusin Ọlọhun o fi sinmi kúrò níbi inira wọn ati awọn ișẹ aburu wọn, dajudaju Oun ni Ọba Ọlọrẹ Alapọn-ọnle.

[2] Sūratul Baqorah, aayah: 102.

Ọlọhun ti mimọ n bẹ fún Un ti ṣe l'ofin fún àwọn ẹrú Rẹ nǹkan ti wọn yíò máa ṣọ́ra kuro nibi aburu idan ṣíwájú ki o to ṣẹlẹ̀, O tun wa ṣàlàyé fún wọn - mimọ n bẹ fún Un- nǹkan ti wọn yìo máa fi ṣe ìwòsàn lẹyin ti o ba ṣẹlẹ, ni eyi ti o jẹ ikẹ lati ọdọ Rẹ fún wọn, ti o si tun jẹ oore lati ọdọ Rẹ si wọn, ti o si tun jẹ pipe idẹra Rẹ le wọn lori.

O n bẹ ninu nǹkan ti o n bọ yìí alaye awọn nkan ti wọn máa n fi wa ààbò kuro nibi ewu idan ṣíwájú ki o to sẹlẹ, ati nkan ti wọn fi máa n ṣe ìwòsàn lẹyin ti o ba ṣẹlẹ nínú àwọn àlámọ̀rí ti o lẹtọọ labẹ ofin Sharia.

Ṣe ẹ wa ri nǹkan ti wọn máa ṣọra pẹlu rẹ kuro níbi ìjànbá idan ṣíwájú ki o to sẹlẹ, èyí tí o pataki julọ ninu rẹ ti o si tun ṣe anfaani julọ ni: Ṣíṣe iṣọra pẹlu awọn adhkār ti o ba ofin Ọlọhun mu ati awọn adura iṣọra ti a jogun ba lọdọ Anabi, ninu rẹ ni kika aayatul kursiyyu lẹyin irun ọranyan lẹyin awọn adhkār ti o ba òfin mu ti a máa n ṣe lẹ́yìn salamọ, ninu rẹ náà tun ni kika a (aayatul kursiyyu) ni àsìkò oorun, àti pé aayatul kursiyyu ni aayah ti o tobi

julọ ninu Kuraani Alapọn-ọnle, oun náà sì ni gbólóhùn Ọba tí mimọ n bẹ fún Un ti o sọ pe:

﴿ٱللَّهُ لَآ إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ ٱلۡحَيُّ ٱلۡقَيُّومُۚ لَا تَأۡخُذُهُۥ سِنَةٞ وَلَا نَوۡمٞۚ لَّهُۥ مَا فِي ٱلسَّمَٰوَٰتِ
وَمَا فِي ٱلۡأَرۡضِۗ مَن ذَا ٱلَّذِي يَشۡفَعُ عِندَهُۥٓ إِلَّا بِإِذۡنِهِۦۚ يَعۡلَمُ مَا بَيۡنَ أَيۡدِيهِمۡ وَمَا
خَلۡفَهُمۡۖ وَلَا يُحِيطُونَ بِشَيۡءٖ مِّنۡ عِلۡمِهِۦٓ إِلَّا بِمَا شَآءَۚ وَسِعَ كُرۡسِيُّهُ ٱلسَّمَٰوَٰتِ
وَٱلۡأَرۡضَۖ وَلَا يَـُٔودُهُۥ حِفۡظُهُمَاۚ وَهُوَ ٱلۡعَلِيُّ ٱلۡعَظِيمُ ٢٥٥﴾ [البقرة: 255]

“**Alloohu laa ilaaha illaa huwal Hayyul kọyyuum laa tah’husuhuu sinatun walaa naom lahuu maa fis samaawaati wa maa fil ardi man zal lazii yash’fahu indahuu illaa bi iznihii yah’lamu maa baena aydiihim wamaa hal’fahum walaa yuhiituuna bi shay’hin min il’mihii illaa bimaa shaa’ha wasiha kursiyyuhuus**

**samaawaati wal ardọ walaa yahuuduhuu hifzuhumaa wahuwal Aliyyul Aziim"**[3]

Ninu ìyẹn naa ni kika:

﴿قُلۡ هُوَ ٱللَّهُ أَحَدٌ ١﴾ [الإخلاص: 1]

**{Kul uwa Allahu Ahad}** [4], ati

﴿قُلۡ أَعُوذُ بِرَبِّ ٱلۡفَلَقِ ١﴾ [الفلق: 1]

**{Kul a'ūdhu bi Robbil falaqi}** [5], ati

﴿قُلۡ أَعُوذُ بِرَبِّ ٱلنَّاسِ ١﴾ [الناس: 1]

**{Kul a'ūdhu bi Robbin nāsi}** [6],

---

3 Sūratul Baqorah, aayah: 255.

4 Suuratul Ikhlaas, Aayah: 1

5 Suuratul Falaq, Aayah:1

6 Suuratun-Naas, Aayah: 1

lẹyin gbogbo irun ọranyan ati kika awọn sūrah wọnyii ni ẹẹmẹta ni ibẹrẹ ọsan lẹ́yìn irun al-fajri, ati ni ibẹrẹ òru lẹyin irun Magrib, ati ni àsìkò oorun, ninu ìyẹn náà ni kika aaya meji ti o gbẹyin Sūratul Baqorah ni ibẹrẹ òru, awọn naa sì ni gbólóhùn Ọba tí ọla Rẹ ga tó sọ pé:

﴿ءَامَنَ ٱلرَّسُولُ بِمَآ أُنزِلَ إِلَيۡهِ مِن رَّبِّهِۦ وَٱلۡمُؤۡمِنُونَۚ كُلٌّ ءَامَنَ بِٱللَّهِ وَمَلَٰٓئِكَتِهِۦ وَكُتُبِهِۦ وَرُسُلِهِۦ لَا نُفَرِّقُ بَيۡنَ أَحَدٖ مِّن رُّسُلِهِۦۚ وَقَالُواْ سَمِعۡنَا وَأَطَعۡنَاۖ غُفۡرَانَكَ رَبَّنَا وَإِلَيۡكَ ٱلۡمَصِيرُ٢٨٥﴾ [البقرة: 285]

“**Āmana ar–rasūlu bimā unzila ilayhi min rabbihi walmu‘minūna kullun amana billahi wamalāikatihi wakutubihi warusulihi la nufarriqu bayna ’ahadin min rusulihi waqālu sami‘na wa’ata‘na ghufranaka rabbana wa–ilayka al–masīr**” [7]**Titi dé ìparí Sūrah**.

7 Sūratul Baqorah, aayah: 285.

O tun ni alaafiaa lati ọdọ ojiṣẹ Ọlọhun (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wipe o sọ pe: Ẹnikẹni ti o ba ka aayatul-kursiy ni òru kan, ko nii yẹ ko nii gbo ni ẹniti oluṣọ kan lati ọdọ Ọlọhun yio máa bẹ pẹlu rẹ, eṣu o si nii sunmọ ọn titi yoo fi di aarọ. O tun ni àlàáfíà lati ọdọ rẹ bakanna (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wipe o sọ pe: (Ẹnikẹni ti o ba ka aayah mejeeji ti o gbẹyin Suuratul-Baqoroh ni alẹ kan, wọn ti to fun un), Itumọ naa ni- Ọlọhun ni O si ni imọ julọ: Méjèèjì ti to fún un kuro nibi gbogbo aburu. Ninu rẹ naa ni pipọ nibi mimaa wa iṣọra pẹlu (awọn gbolohun Ọlọhun ti o pe perepere kuro nibi aburu awọn nnkan ti O da) ni oru ati ọsan ati nibi sisọkalẹ sí ààyè kaaye ni inú ilu tabi papa tabi ori òfurufú tabi ori omi, fun ọrọ Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ti o sọ pe: ' Ẹnikẹni ti o ba sọkalẹ si aaye kan ti o wa sọ pe: " A ‘ūdhu bikalmaatiLlaahi at-taamah min sharri maa khalaq", nkankan o nii ni í lara titi yíò fi kuro ni ààyè rẹ yẹn. Ninu rẹ náà tún ni ki musulumi o maa sọ ni ibẹrẹ ọsan ati ibẹrẹ alẹ ni ẹẹmẹta pe: “Bismillāhi lladhi lā yadurru ma ‘ha

ismihi shayhun fil ardi wala fis samā’i wa Uwa as-Samī ‘u al- ‘Alīm”. Fun lilaafia siṣeni ni ojukokoro lọ sibi ìyẹn lati ọdọ ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a), ati pe ìyẹn tun jẹ okùnfà fun lila kuro nibi gbogbo aburu. Ati pe awọn iranti ati iṣọra yii wa ninu awọn okunfa ti o tobi julọ nibi sisọra kuro nibi aburu asasi ati ohun ti o yatọ si i ninu awọn aburu ti yoo maa bẹ fun ẹnikẹni ti o ba dunni mọ ọn pẹlu otitọ, ati igbagbọ, ati igbarale Ọlọhun, ati fifi ara ti I ati ìṣípayá ọkan fun ohun ti o da le lori. O si tun jẹ ohun ìjà ti o tobi julọ lati fi mu asasi kuro lẹyin igba ti o ti ṣẹlẹ, pẹlu pipọ ni idirẹbẹ lọ sí ọdọ Ọlọhun ati mimaa bi I leere lati mu inira naa lọ ati lati mu ìdààmú kuro. Ninu awọn adua ti o fi ẹsẹ rinlẹ ti o wa lati ọdọ rẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) nibi iwosan fun awọn aisan bii asasi ati ohun ti o yatọ si i - O jẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ẹnití maa n ṣe rukiya fun awọn saabe rẹ pẹlu rẹ: “Allahummo robban nās az'hibil bah's, wash'fi antash shāfi, laa shifāha illā shifāhuka, shifāhan laa yugādiru saqoman”. Yoo maa wi i lẹẹmẹta, ati pe lara rẹ naa ni

rukiya ti Jubriil ka fun Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) oun naa ni: “Bismillāhi arqīka min kulli shay’in yu’dhīka wa min sharri kulli nafsin ao aynin hāsidin Allāhu yashfīka bismiLlāhi arqīka” Ki o maa paara rẹ ni ẹẹmẹta Ninu iwosan asasi lẹyin igba ti o ba ṣẹlẹ ti o si jẹ iwosan kan ti o ṣe anfaani fun ọkùnrin ti wọn ba de e mọlẹ lati ma baa lee sunmọ ìyàwó rẹ, ki o mu ewe meje ninu ewe sidiru ti o tutu, kí o wa lọ ọ pẹlu okuta abi ohun ti o jọ ọ, kí o wa ko o sinu abọ ki o wa da omi ti yíò to o wẹ sí i, kí o wa ka sinu rẹ aayatul-kursiyy, ati

﴿قُلۡ يَٰٓأَيُّهَا ٱلۡكَٰفِرُونَ ١﴾ [الكافرون: 1]

"**Qul–Yaa ayuhal kaafiruun**"[8]

﴿قُلۡ هُوَ ٱللَّهُ أَحَدٌ ١﴾ [الإخلاص: 1]

"**Qul uwa Llaahu Ahad** ",[9]

---

[8] Suuratul-kaafiruun, Aayah: 1

[9] Suuratul Ikhlaas, Aayah: 1

﴿قُلۡ أَعُوذُ بِرَبِّ ٱلۡفَلَقِ ١﴾ [الفلق: 1]

"**Qul a‘udhu birobbil falaq**" [10],

﴿قُلۡ أَعُوذُ بِرَبِّ ٱلنَّاسِ ١﴾ [الناس: 1]

"**Qul a‘udhu birobbin naas** ",[11]

Ati awọn aaya idan ti o wa ninu suuratul a'raaf, oun naa ni ọrọ Rẹ (Ọlọhun) :

﴿۞ وَأَوۡحَيۡنَآ إِلَىٰ مُوسَىٰٓ أَنۡ أَلۡقِ عَصَاكَۖ فَإِذَا هِيَ تَلۡقَفُ مَا يَأۡفِكُونَ ١١٧ فَوَقَعَ ٱلۡحَقُّ وَبَطَلَ مَا كَانُواْ يَعۡمَلُونَ ١١٨ فَغُلِبُواْ هُنَالِكَ وَٱنقَلَبُواْ صَٰغِرِينَ ١١٩﴾ [الأعراف: 117-119]

10 Suuratul Falaq, Aayah:1

11 Suuratun-Naas, Aayah:1

**A sì fi ìmísí ránṣẹ́ sí (Ànábì) Mūsā pé : "Ju ọ̀pá rẹ sílẹ̀." Nígbà náà, ó sì ń gbé ohun tí wọ́n ti pa níró kalẹ̀ mì kálókáló. Nítorí náà, òdodo dé. Ohun tí wọ́n ń ṣe níṣẹ́ sì bàjẹ́. Nítorí náà, A borí wọn níbẹ̀ yẹn. Wọ́n sì darí wálé ní ẹni yẹpẹrẹ.**[12]

Ati awọn aayah ti o wa ninu suuratu Yuunus, oun naa ni ọrọ Rẹ (mímọ́ ni fun Un)

﴿وَقَالَ فِرۡعَوۡنُ ٱئۡتُونِي بِكُلِّ سَٰحِرٍ عَلِيمٖ ٧٩ فَلَمَّا جَآءَ ٱلسَّحَرَةُ قَالَ لَهُم مُّوسَىٰٓ أَلۡقُواْ مَآ أَنتُم مُّلۡقُونَ ٨٠ فَلَمَّآ أَلۡقَوۡاْ قَالَ مُوسَىٰ مَا جِئۡتُم بِهِ ٱلسِّحۡرُۖ إِنَّ ٱللَّهَ سَيُبۡطِلُهُۥٓ إِنَّ ٱللَّهَ لَا يُصۡلِحُ عَمَلَ ٱلۡمُفۡسِدِينَ ٨١ وَيُحِقُّ ٱللَّهُ ٱلۡحَقَّ بِكَلِمَٰتِهِۦ وَلَوۡ كَرِهَ ٱلۡمُجۡرِمُونَ ٨٢﴾ [يونس: 79-82]

12 Suuratul-A'raaf, aayah: 117-119.

:"**Fir ‘aon wí pé**: “**Ẹ lọ mú gbogbo àwọn onímọ̀ nípa idán pípa wá fún mi**.” **Nígbà tí àwọn òpìdán sì dé**, (**Ànábì**) **Mūsā sọ fún wọn pé**: “**Ẹ ju ohun tí ẹ máa jù sílẹ̀**.” **Nígbà tí wọ́n jù ú sílẹ̀**, (**Ànábì**) **Mūsā sọ pé**: “**Idán ni ohun tí ẹ mú wá**. **Dájúdájú Allāhu sì máa bà á jẹ́**. **Dájúdájú Allāhu kò sì níí ṣàtúnṣe iṣẹ́ àwọn òbìlẹ̀jẹ́**. **Allāhu sì máa mú òdodo ṣẹ pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ Rẹ̀**,"13

àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀ ìbáà kórira rẹ̀. Ati awọn aayah ti o wa ninu suuratu Tooha :

﴿قَالُواْ يَٰمُوسَىٰٓ إِمَّآ أَن تُلۡقِيَ وَإِمَّآ أَن نَّكُونَ أَوَّلَ مَنۡ أَلۡقَىٰ ٦٥ قَالَ بَلۡ أَلۡقُواْۖ فَإِذَا حِبَالُهُمۡ وَعِصِيُّهُمۡ يُخَيَّلُ إِلَيۡهِ مِن سِحۡرِهِمۡ أَنَّهَا تَسۡعَىٰ ٦٦ فَأَوۡجَسَ فِي نَفۡسِهِۦ خِيفَةٗ مُّوسَىٰ ٦٧ قُلۡنَا لَا تَخَفۡ إِنَّكَ أَنتَ ٱلۡأَعۡلَىٰ ٦٨ وَأَلۡقِ مَا فِي يَمِينِكَ تَلۡقَفۡ مَا صَنَعُوٓاْۖ إِنَّمَا صَنَعُواْ كَيۡدُ سَٰحِرٖۖ وَلَا يُفۡلِحُ ٱلسَّاحِرُ حَيۡثُ أَتَىٰ ٦٩﴾ [طه: 79-82]

13 Suuratu-Yuunus, aayah 79-82.

**(Àwọn òpìdán) wí pé : “Mūsā, ìwọ ni o máa kọ́kọ́ ju (ọ̀pá sílẹ̀ ni) tàbí àwa ni a óò kọ́kọ́ jù ú sílẹ̀.” (Mūsā) sọ pé : “Ẹ ju (tiyín) sílẹ̀ (ná).” Nígbà náà ni àwọn okùn wọn àti ọ̀pá wọn bá ń yíra padà lójú rẹ̀ nípasẹ̀ idán wọn, bí ẹni pé dájúdájú wọ́n ń saré. (Ànábì) Mūsā sì pa ẹ̀rù inú ọkàn rẹ̀ mọ́ra. A sọ pé : "Má ṣe páyà. Dájúdájú ìwọ, ìwọ lo máa lékè. Ju ohun tí ń bẹ ní ọwọ́ ọ̀tún rẹ sílẹ̀. Ó sì máa gbé ohun tí wọ́n ṣe kalẹ̀ mì káló. Dájúdájú ohun tí wọ́n ṣe kalẹ̀, ète òpìdán ni. Òpìdán kò sì níí jèrè ní ibikíbi tí ó bá dé."**[14]

Lẹyin kike awọn nnkan ti a darukọ sinu omi, yoo mu gẹẹ mẹta ninu rẹ, yoo si fi eleyii ti o ku wẹ, pẹlu ṣiṣe ìyẹn aisan naa o kuro ti Ọlọhun ba fẹ, ti bukaata ba pepe lọ sibi

[14] Suuratu-toha, aayah: 65-69.

lilo o ni ẹẹmeji abi ju bẹẹ lọ, ko si laifi nibẹ titi ti aisan naa a fi lọ.

Bakannaa ninu iwosan asasi - o si wa ninu eyiti o ṣe anfaani julọ ninu iwosan rẹ - oun naa ni ṣiṣe igbiyanju láti mọ aaye asasi naa lori ilẹ abi lori oke abi ibi ti o yatọ si i, ti wọn ba ti mọ ọn, ti wọn si mu un jade, ti wọn si ba a jẹ, asasi naa ti bajẹ.

Eleyii ni ohun ti alaye rẹ rọrun ninu awọn alamọri ti a le wa iṣọra pẹlu rẹ kúrò nibi asasi, ti wọn si le ṣe iwosan pẹlu rẹ. Ọlọhun ni O ni akoso ifiniṣe-kongẹ.

Àmọ́ mimaa ṣe iwosan rẹ pẹlu iṣẹ awọn opidan, eleyii ti o ṣe pé òun ni sisunmọ alijannu pẹlu didunbu nnkan tabi nnkan ti o yatọ si i ninu awọn nnkan ti a fi n sunmọ nnkan, eleyii ko lẹtọọ ; nitori pe ninu iṣẹ eṣu ni o wa, bi bẹẹ tiẹ kọ ninu ẹbọ ti o tobi lo wa. Eleyii ti o jẹ dandan naa ni ṣiṣọra kuro nibẹ, gẹgẹbi ṣiṣe iwosan rẹ ko ṣe lẹtọọ pẹlu imaa bi awọn adagbigba (aworawọ) leere, ati awọn yẹmiwo ati awọn opidan, ati ṣíṣe àmúlò awọn nnkan ti

wọn n sọ ; nitori pe wọn ko gbagbọ, ati pe opurọ onibajẹ ni wọn ti wọn si n pe apemọra imọ kọkọ, ti wọn si n da nǹkan ru fún awọn eeyan. Ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) si ti ṣe ikilọ kúrò nibi lílọ maa ba wọn, ati mimaa bi wọn leere, ati gbigba wọn lododo, gẹgẹ bi alaye rẹ ṣe ṣíwájú nibi ìbẹ̀rẹ̀ tira yii. Ati pe ẹgbawa ti o ni alaafia wa lati ọdọ Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba) pe wọn bi i leere nipa An-nushrọ, o si sọ pe : O wa ninu iṣẹ eṣu Imaam Ahmad ati Abu Daa'ud ni wọn gba a wa pẹlu Isnaad ti o dara. An-nushro : Òun ni titu asasi kuro lara ẹniti wọn sa si. Ati pe èròngbà rẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) pẹlu ọrọ rẹ yii ni : An-nushro ti awọn ara àsìkò ki Islām to de máa n ṣe, oun naa ni mimaa bi opidan leere lati tu asasi, abi lati tu u (asasi) pẹlu idan ti o jọ o lati ọdọ opidan miran.

Àmọ́ titu u (asasi) pẹlu ruqyah ati pẹlu awọn iṣọra ti o ba ofin ẹsin mu ati awọn oogun ti o tọ, ko si laifi nibẹ gẹgẹ bi o ṣe ṣaaju. Olumọ agba, Ibn Qayyim, ti sọrọ lori ìyẹn,

ati Shaykh Abdur-Rah'man ọmọ Hasan ninu tira Fat’hul Majeed, ikẹ Ọlọhun ki o maa bẹ lori awọn mejeeji, awọn ti o yatọ si awọn mejeeji nínú awọn olumọ naa si tun sọrọ lórí rẹ bákannáà.

Ọlọhun ni a n bẹ ki O fi awọn musulumi ṣe kongẹ alaafia kuro nibi gbogbo aburu, ati lati ṣọ ẹsin wọn fun wọn, ati lati rọ wọn lọrọ agbọye ninu rẹ, ati lati la wọn kuro nibi gbogbo nkan ti yíò yapa ofin Rẹ, Ki Ọlọhun ṣe ikẹ ati igẹ fun ẹrusin Rẹ ati Ojiṣẹ Rẹ tii ṣe Muhammad ati awọn araale rẹ ati awọn saabe rẹ.

## Asasi iyawo si ọkọ [16]

Lati ọdọ Abdul-Azeez ọmọ Abdullaah ọmọ Baaz lọ si ọdọ ọmọ iya alapọn-ọnle... Alaafia, ikẹ, ati awọn alubarika Ọlọhun maa wa pẹlu yin, lẹyin naa :

Ìwé yin de ọdọ mi l'eyiti ko ni déètì- Ọlọhun yio dà yín pọ pẹlú imọna Rẹ - ati nkan ti o ko sinu ni ifitonileti nipa nnkan ti o ṣẹlẹ sí yin nígbà tí o fẹ sunmọ iyawo rẹ tuntun ati lilọ rẹ si ọdọ Shaykh ati fat'wah ti o ṣe fun ọ, ati nipa nǹkan ti iyawo ti tẹlẹ ṣe ti o jẹ okunfa aile sunmọ iyawo rẹ tuntun, ati pe ibeere rẹ nipa idajọ yii si jẹ nkan ti a mọ. Idahun ni pé : Ti iyawo ti tẹlẹ ba jẹwọ pe oun ni oun ṣe iṣẹ yii, tabi ti o ba da lé e lori pẹlu ẹri, o ti ṣe ibajẹ nla, kódà o ti ṣe iṣẹ́ keferi ati anu ; tori pe iṣẹ rẹ yii jẹ idan/asasi ti o jẹ eewọ. Opidan si jẹ keferi gẹgẹ bi Ọlọhun (ti O mọ julọ) ṣe sọ pe : Wọ́n sì tẹ̀lé ohun tí àwọn èṣù àlùjànnú ń kà (fún wọn nínú idán) lásìkò ìjọba (Ànábì) Sulaemọ̄n. (Ànábì) Sulaemọ̄n kò sì ṣàì gbàgbọ́, ṣùgbọ́n àwọn èṣù àlùjànnú ni wọ́n ṣàì gbàgbọ́, tí wọ́n ń kọ́ àwọn

ènìyàn ní idán. Àwa kò sì sọ (idán) kalẹ̀ fún àwọn mọlāika méjì náà. (Àmọ́ àwọn èṣù àlùjànnú wọ̀nyí) Hārūt àti Mọ̄rūt ní (ìlú) Bābil (ni wọ́n ń kọ́ àwọn ènìyàn nídán). Wọn kò sì níí kọ́ ẹnikẹ́ni àyàfi kí wọ́n wí pé :

﴿وَٱتَّبَعُواْ مَا تَتۡلُواْ ٱلشَّيَٰطِينُ عَلَىٰ مُلۡكِ سُلَيۡمَٰنَۖ وَمَا كَفَرَ سُلَيۡمَٰنُ وَلَٰكِنَّ ٱلشَّيَٰطِينَ كَفَرُواْ يُعَلِّمُونَ ٱلنَّاسَ ٱلسِّحۡرَ وَمَآ أُنزِلَ عَلَى ٱلۡمَلَكَيۡنِ بِبَابِلَ هَٰرُوتَ وَمَٰرُوتَۚ وَمَا يُعَلِّمَانِ مِنۡ أَحَدٍ حَتَّىٰ يَقُولَآ إِنَّمَا نَحۡنُ فِتۡنَةٞ فَلَا تَكۡفُرۡۖ فَيَتَعَلَّمُونَ مِنۡهُمَا مَا يُفَرِّقُونَ بِهِۦ بَيۡنَ ٱلۡمَرۡءِ وَزَوۡجِهِۦۚ وَمَا هُم بِضَآرِّينَ بِهِۦ مِنۡ أَحَدٍ إِلَّا بِإِذۡنِ ٱللَّهِۚ وَيَتَعَلَّمُونَ مَا يَضُرُّهُمۡ وَلَا يَنفَعُهُمۡۚ وَلَقَدۡ عَلِمُواْ لَمَنِ ٱشۡتَرَىٰهُ مَا لَهُۥ فِي ٱلۡأٓخِرَةِ مِنۡ خَلَٰقٖۚ وَلَبِئۡسَ مَا شَرَوۡاْ بِهِۦٓ أَنفُسَهُمۡۚ لَوۡ كَانُواْ يَعۡلَمُونَ ١٠٢﴾ [البقرة: 102]

**"Àdánwò ni wá. Nítorí náà, má di kèfèrí." Wọ́n sì ń kẹ́kọ̀ọ́ ohun tí wọn yóò fi ṣòpínyà láàárin ọmọnìyàn àti ẹnì kejì rẹ̀ lọ́dọ̀ àwọn àlùjànnú méjèèjì. – Wọn kò sì lè kó ìnira bá ẹnikẹ́ni àyàfi pẹ̀lú ìyọ̀ǹda Allāhu. – Wọ́n ń kẹ́kọ̀ọ́ ohun tí ó máa kó ìnira bá wọn, tí kò sì níí ṣe wọ́n ní àǹfààní. Wọ́n kúkú ti mọ̀ pé ẹnikẹ́ni tí ó bá ra idán, kò níí sí ìpín rere kan fún un ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn. Aburú sì ni ohun tí wọ́n rà fún ẹ̀mí ara wọn tí ó bá jẹ́ pé wọ́n mọ̀.**[15]

Aayah alapọnle yii n da lori wipe idan iṣe keferi ni, ati pe dajudaju opidan keferi ni, ati pe dajudaju awọn opidan maa n kọ nkan ti yíò maa ko inira ba wọn ti ko si nii ṣe wọn ni anfaani, ati pe dajudaju ninu awọn erongba wọn ni ṣiṣe opinya laarin iyawo ati ọkọ rẹ, ati pe dajudaju ko si ipin

15 Sūratul Baqoroh, Ayah: 102. "

kankan fun wọn lọdọ Ọlọhun lọjọ igbende - iyẹn ni pe ko si ipin kankan fun wọn nibi lila. O wa ninu Hadiisi ti o ni alaafia lati ọdọ ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- pe o sọ pe :" (Ẹ jina si awọn nnkan meje ti o maa n ko iparun ba èèyàn) " Wọn so pe : kini wọn iwọ ojiṣẹ Ọlọhun ? O sọ pe : " (Dida orogun pọ mọ Ọlọhun, ati idan ati pipa ẹmi ti Ọlọhun ṣe leewọ ayafi pẹlu ẹtọ, ati jijẹ owo ele, ati jijẹ owo ọmọ orukan, ati sisa ni ojú ogun, ati pipa irọ àgbèrè mọ àwọn ọmọlúàbí (ti wọn kii ṣe onisekuse) l'óbìnrin, àwọn tí sìná kò sí lórí ọkàn wọn, àwọn onígbàgbọ́ òdodo lóbìnrin.

Ṣe o wa ri Sheikh ti o fun ẹ ni oògùn naa, eyi ti o foju han ni pé dajudaju onidan ni gẹgẹ bii obinrin naa, nitori pe ko si ẹni tí o le mọ nipa idan ayafi awọn onidan, àti pé o tun jẹ ọkan ninu awọn yẹmiwo ati awọn alagbigba (aworawọ) awọn ti wọn mọ pẹlu pipe apemọra imọ nipa kọkọ nibi ọpọlọpọ awọn alamọri, nǹkan ti o wa jẹ dandan fun musulumi ni ki o sọra fun wọn ki o si ma gba wọn lododo nipa nnkan ti wọn ba n pé apemọra rẹ nipa imọ kọkọ fun ọrọ

Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- tó sọ pe:" (Ẹniti o ba lọ ba yẹmiwo ti o wa bi i leere nipa nnkankan, wọn kò nii gba irun rẹ fun ogoji ọjọ) Muslim ni o gbe e jade ninu sohiihu rẹ, ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- tun sọ pé : Ẹnití o ba wa ba yẹmiwo kan tabi adadigba kan, ti o wa gba a l'ododo pẹlu nkan ti o n sọ, o ti ṣe aigbagbọ pẹlu nkan ti wọn sọkalẹ fún Muhammad (kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a) Nitori naa nnkan ti o jẹ dandan fun ọ ni ituba ati kika abamọ lori nnkan ti o ṣẹlẹ lati ọdọ rẹ, kí o tun fún olori ikọ alamojuto ati olori ile ẹjọ ni iro nipa Sheikh ti o sọ ati iyawo rẹ tẹ́lẹ̀ rí, titi ti ile ẹjọ ati ikọ alamojuto o fi ṣe nnkan ti o maa da wọn lọwọ kọ ti iru iṣẹlẹ yii ba ṣẹlẹ si ọ, yaa lọ bere lọwọ awọn olumọ sharia ki wọn le sọ fún ọ iwosan ti sharia. Ki Ọlọhun rọ awa ati iwọ lọrọ agbọye ninu ẹsin ati ifi ẹsẹ rinlẹ lori ẹ, ati lila kuro nibi nnkan ti yíò yapa rẹ, dajudaju Òun ni Ọba Ọlọrẹ Ọba Alapọn-ọnle. "

Ki alaafia ati ikẹ Ọlọhun ati alubarika rẹ maa ba yin.

## Ìdájọ́ bibeere nǹkan lọwọ awọn onidan ati awọn ti n pawọda [18]

Ibeere : Arákùnrin : ب .ع .ص. Lati Riyadh, o sọ ninu ibeere rẹ pé: Àwọn eeyan kan n bẹ ni awọn apa ibi kan ni Yemen ti wọn n pe wọn ni: (As saadat) awọn eeyan yii si maa n mu awọn nnkan ti o tako ẹsin wa gẹ́gẹ́ bíi pipawọda ati nnkan to yatọ si i, ti wọn si maa n sọ pe awọn ni ikapa lori wiwo awọn eeyan san nibi awọn aisan ti wọn kò ri iwosan rẹ, ti wọn si maa fi ìdí rẹ múlẹ̀ pẹlu gigun ara wọn ni ọbẹ tabi gige ahọn wọn, lẹyin naa wọn maa da a pada laisi ìnira kankan ti o maa kan wọn, o si wa ninu wọn awọn ti máa n kirun, ó si tun wa ninu wọn awọn ti kii kirun. Bákannáà wọn maa n ṣe fifẹ ẹnití kii ṣe ara ẹbí wọn lẹtọọ fún ara wọn, ti wọn kò sì ṣe e lẹtọọ fún ẹnikẹ́ni fífẹ ẹbi wọn, ti wọn bá sì tun n ṣe adua fún àwọn aláìsàn wọn a maa sọ nibẹ pe : (Yaa Allahu yaa fulaan) “Irẹ Ọlọhun irẹ lágbájá” ikan ninu awọn baba baba wọn." Nigba láíláí (tipẹ tipẹ) awọn eeyan maa n gbe wọn tobi,

ti wọn tun máa n wo wọn bi ẹnití kii ṣe èèyàn lásán, ati pe wọn jẹ alasunmọ Ọlọhun, koda awọn ẹni Ọlọhun ni wọn maa n pe wọn, àmọ́ báyìí, awọn eeyan ti pin nipa wọn, o wa ninu wọn awọn ti wọn máa n tako wọn, awọn yẹn ni awọn ọdọ ati awọn kan nínú àwọn akẹ́kọ̀ọ́, o si wa ninu wọn awọn ti wọn o yẹ ni ẹniti o n dirọ mọ wọn, awọn yẹn ni awọn àgbàlagbà ati awọn ti wọn kii ṣe akẹ́kọ̀ọ́. A n fẹ lati ọdọ yin alaye tòótọ́ nipa ọ̀rọ̀ yii. Idahun : Àwọn wọnyii ati awọn to jọ wọn wa ninu awọn suufi ti o ṣe pe awọn isẹ buruku ati awọn iwa ibajẹ ń bẹ fún wọn, bakanna wọn tun wa ninu awọn yẹmiwo, awọn ti o ṣe pe Anọbi sọ nipa wọn- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pe : Ẹnití o ba wa ba yẹmiwo kan ti o wa bi i leere nipa nkankan, wọn ko nii gba irun rẹ fún ogoji ọjọ. Iyẹn ri bẹẹ latara ipepe ìmọ̀ kọkọ wọn, ati ṣíṣe ídímọ́ wọn fun awọn alujannu, ati fifi jijọsin wọn fún awọn alujannu, ati idarudapọ wọn fún awọn eeyan pẹlu nnkan tí wọn n ṣe ninu oríṣiríṣi idan ti Ọlọhun sọ nipa rẹ nibi itan Anọbi Musa ati Fir'haon pe : (Ànábì Mūsā) sọ pé :

﴿قَالَ أَلْقُوا۟ۖ فَلَمَّآ أَلْقَوْا۟ سَحَرُوٓا۟ أَعْيُنَ ٱلنَّاسِ وَٱسْتَرْهَبُوهُمْ وَجَآءُو بِسِحْرٍ عَظِيمٍ ١١٦﴾ [الأعراف: 116]

“**Ẹ ju** (**tiyín**) **sílẹ̀** (**ná**).” **Nígbà tí wọ́n jù ú sílẹ̀**, **wọ́n fi pidán lójú àwọn ènìyàn**. **Wọ́n sì ṣẹ̀rùbà wọ́n**. **Wọ́n wá pẹ̀lú idán ńlá**.)[16]

Ko tọ lati lọ ba wọn ati bibeere lọwọ wọn fun Hadiisi abiyi yii, ati fun ọrọ rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- pe : Ẹnití o ba wa ba yẹmiwo kan ti o si gba a l'ododo pẹlu nkan ti o n sọ, ẹni naa ti ṣe aigbagbọ pẹlu nǹkan ti wọn sọkalẹ fún Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a). Ninu gbolohun mìíràn :" Ẹnití o ba wa ba yẹmiwo kan tabi adadigba kan, ti o wa gba a l'ododo pẹlu nkan ti o n sọ, o ti ṣe aigbagbọ pẹlu nkan ti wọn sọkalẹ fún Muhammad (kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a).

16 Surah Al A'raf, Ayah: 116."

Amọ pipe ẹniti o yatọ si Ọlọhun wọn ati iwa ìgbàlà wọn sọdọ ẹniti o yatọ si Ọlọhun, tabi lilero wọn pe dajudaju awọn baba wọn ati awọn aṣáájú wọn lè ṣe ohunkohun ninu aye, tabi wọn n wo awọn alaarẹ san, tabi wọn maa n gba adua lẹ́yìn ikú wọn tàbí àìsí ní tòsí wọn Gbogbo eyi patapata wa ninu iṣe aigbagbọ ninu Ọlọhun ti O biyi ti O si gbọnngbọn, o si tun wa ninu ẹbọ nla, nitori naa nnkan to jẹ dandan ni titako wọn ati ki èèyàn ma si lọ bá wọn, ati ki èèyàn ma si beere nǹkan kan lọwọ wọn, ati ki èèyàn ma gba wọn lododo, nítorí pé wọn ko papọ sinu awọn iṣẹ́ yii laarin awọn iṣẹ́ awọn adagbigba ati yẹmiwo, ati laarin iṣẹ awọn ọsẹbọ ti wọn jẹ ẹrusin fún nnkan ti o yatọ si Ọlọhun ti wọn n wa ìgbàlà pẹlu nnkan ti o yatọ si Ọlọhun, ti wọn n wa iranlọwọ pẹlu nnkan ti o yatọ si Ọlọhun, ninu awọn alujannu ati awọn oku ati awọn to yatọ si wọn ninu awọn ti wọn ṣe afiti ara wọn si lọ́dọ̀, ti wọn sì n ni lero pe dajudaju awọn baba wọn ati awọn aṣáájú wọn ni wọn tabi ninu awọn eeyan miiran, ti wọn n lero pe ijẹ ààyò tabi apọnle nbẹ fun wọn, amọ sá gbogbo eyi wa ninu

awọn iṣẹ ipawọda (ẹtanjẹ) ati ninu awọn iṣẹ́ adagbigba ati yẹmiwo, eleyii ti ofin sharia ti o mọ kanga takò.

Sugbọn nnkan ti o maa n sẹlẹ ninu awọn iwa wọn ti ko dara (ti a kọ) nibi gigun ara wọn pẹlu ọbẹ tabi gige ahọn ara wọn, gbogbo eyi patapata jẹ dída nnkan ru (ẹtanjẹ) fun awọn eeyan, gbogbo ẹ tun wa ninu oríṣirísị idan ti wọn ṣe leewọ to ṣe pe awọn ẹri lati inu Qur'an ati Hadiisi wa lori ṣiṣe e leewọ ati ṣíṣe ikilọ kuro nibẹ gẹ́gẹ́bí o ti ṣe ṣáájú, ko si lẹtọọ fun oni làákàyè lati gba ẹtanjẹ pẹlu ẹ, eleyii si tun wa ninu irú nnkan ti Ọlọhun sọ nipa awọn onidan fir’haon pe :"

﴿قَالَ بَلۡ أَلۡقُواْۖ فَإِذَا حِبَالُهُمۡ وَعِصِيُّهُمۡ يُخَيَّلُ إِلَيۡهِ مِن سِحۡرِهِمۡ أَنَّهَا تَسۡعَىٰ ٦٦﴾ [طه: 66]

**{wọn bá ń yíra padà lójú rẹ̀ nípasẹ̀ idán wọn, bí ẹni pé dájúdájú wọ́n ń sáré.}**[17]

---

[17] Suuratu Toha, ayah: 66. "

Nitori naa awọn eeyan wọ̀nyí ti ko papọ idan ati pipawọda ati didagbigba (wiwo irawọ) ati ṣíṣe yẹmiwo, ati laarin ẹbọ nla ati iwa iranlọwọ pẹlu nnkan ti o yatọ si Ọlọhun, ati iwa igbala pẹlu nnkan ti o yatọ si Ọlọhun, ati pípe apemọra ìní imọ kọkọ ati ṣíṣe bi o ṣe wu wọn nibi imo aye, eléyìí ni awọn iran tó pọ̀ ninu ẹbọ nla ati ṣíṣe aigbagbọ to fojuhan, ati ninu awọn iṣẹ́ ipawọda ti Ọlọhun ṣe leewọ ati ninu pipe apemọra ìní imọ kọkọ ti ko si ẹniti o ni imọ nipa rẹ ayafi Ọlọhun, gẹgẹbi Ọlọhun ṣe sọ pe: Sọ pé:

﴿قُل لَّا يَعۡلَمُ مَن فِي ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضِ ٱلۡغَيۡبَ إِلَّا ٱللَّهُۚ وَمَا يَشۡعُرُونَ أَيَّانَ يُبۡعَثُونَ﴿٦٥﴾﴾ [النمل: 65]

**“Àwọn t’ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ kò nímọ̀ ìkọ̀kọ̀ àfi Allāhu".**[18]

---

[18] Suuratun Naml, ayah: 65. "

. Nnkan ti o wa jẹ dandan lori gbogbo Musulumi ti o ni imọ nipa wọn ni titako wọn ati ṣíṣe alaye aburu awọn ìṣesí wọn pe awọn ìṣesí ti a kọ ni, ati gbigbe alamọri wọn lọ sí ọdọ awọn olori

Ti wọn ba wa ni awọn ilu Isilaamu titi ti wọn yíò fi fi iya jẹ wọn pẹlu nnkan ti wọn ni ẹtọ si ninu sharia lati fi dẹkun aburu wọn ati lati daabo bo awọn musulumi kuro nibi awọn ibajẹ wọn ati awọn idarudapọ wọn.

Ọlọhun ni Olufiniṣe-kongẹ"

## Iwosan lọdọ dokita ibilẹ ti n lo alujannu

Ibeere : Àwọn ikọ kan nbẹ ninu awọn eeyan ti wọn n ṣe iwosan pẹlu oògùn ibilẹ ni ìbámu sí ọrọ wọn, igba ti mo wa lọ ba ikan lara wọn, o sọ fún mi pe : kọ orukọ rẹ ati orukọ iya rẹ, lẹyin naa pada wa ba wa ni ọla, ti ẹni naa ba pada lọ bá wọn, wọn maa sọ fun un pe : Dájúdájú wọn ti fi nnkan báyìí báyìí ṣe ọ, nnkan báyìí báyìí si ni iwosan rẹ.... Ọkan ninu wọn a tún máa sọ pe : Ọ̀rọ̀ Ọlọhun ni oun n lo nibi iwosan, kini irori yin nibi iru awọn wọnyi ? Kini idajọ lilọ ba wọn ? غ. ع. س. Ha'il.

Idahun : Ẹni tí o ba n ṣe iru nǹkan yii nibi iwosan rẹ, o n jẹ ẹri lori pe dajudaju o n lo alujannu, ó si tun n pe apemọra imọ awọn nnkan ti o pamọ, nitori naa ṣiṣe iwosan lọdọ rẹ ko tọ, gẹgẹbi lilọ si ọdọ rẹ o ṣe tọ ati bibi i leere ; fun ọrọ ti Anọbi sọ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nibi iru iran awọn eeyan yìí pé : (Ẹniti o ba lọ ba yẹmiwo kan ti o wa bi i leere nipa nnkankan, wọn o nii gba irun rẹ fun ogoji ọjọ) Muslim lo gbe e jade ninu sohiihu rẹ. " O

tun fi ẹsẹ rinlẹ lati ọdọ Rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ninu ọpọlọpọ hadīth, kikọ kúrò nibi lílọ ba awọn adagbigba ati yẹmiwo ati awọn onidan ati kikọ kuro nibi bibi wọn leere ati gbigba wọn lododo, o sọ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- pe : Ẹnití o ba wa ba yẹmiwo kan ti o si gba a l'ododo pẹlu nkan ti o n sọ, ẹni naa ti ṣe aigbagbọ pẹlu nǹkan ti wọn sọkalẹ fún Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a). Ati pe gbogbo ẹniti o ba n pe apemọra imọ kọkọ pẹlu lilo dida okuta wẹwẹ, tabi owo ẹyọ, tabi fifa ila silẹ, tabi bibeere lọwọ alaarẹ nipa orukọ rẹ, tabi orukọ iya rẹ, tabi orúkọ awọn alasunmọ rẹ, gbogbo iyẹn jẹ ẹri lori pe dajudaju o wa ninu awọn yẹmiwo ati alagbigba ti Anọbi - - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - kọ fun wa lati beere lọwọ wọn ati lati gba wọn lododo.

Nnkan to jẹ dandan ni sisọra kuro lọdọ wọn ati kuro nibi bibi wọn leere ati kuro nibi wiwa iwosan lọ sọdọ wọn, koda ki wọn lero pe awọn n ṣe iwosan pẹlu Quran, torí pé ninu iṣesi awọn onibajẹ ni idarudapọ ati ẹtan ;

nítorí náà ko tọ lati gba wọn gbọ nibi nnkan ti wọn ba ń sọ. Nnkan to tun jẹ dandan fun ẹniti o ba mọ ikan ninu wọn ni ki o gbe ọrọ rẹ lọ sọdọ awọn adari ọrọ ninu awọn adajọ ati awọn aláṣẹ, ati awọn ọ́fíìsì àwọn igbimọ to n ri si iru nǹkan yẹn ni gbogbo ilu, titi ti wọn fi maa ṣe idajọ lori wọn pẹlu idajọ Ọlọhun, ati titi ti awọn musulumi o fi la kuro nibi aburu wọn ati ibajẹ wọn ati jijẹ awọn owo awọn eeyan lọna ibajẹ.

Ọlọhun ni a à maa wa iranlọwọ lọ sí ọdọ Rẹ, kò sí ete kan tabi agbara kan ayaafi pẹlu Ọlọhun

## Iwosan ti ilana sharia fun idan [22]

Ibeere :

﴿وَٱتَّبَعُواْ مَا تَتۡلُواْ ٱلشَّيَٰطِينُ عَلَىٰ مُلۡكِ سُلَيۡمَٰنَۖ وَمَا كَفَرَ سُلَيۡمَٰنُ وَلَٰكِنَّ ٱلشَّيَٰطِينَ كَفَرُواْ يُعَلِّمُونَ ٱلنَّاسَ ٱلسِّحۡرَ وَمَآ أُنزِلَ عَلَى ٱلۡمَلَكَيۡنِ بِبَابِلَ هَٰرُوتَ وَمَٰرُوتَۚ وَمَا يُعَلِّمَانِ مِنۡ أَحَدٍ حَتَّىٰ يَقُولَآ إِنَّمَا نَحۡنُ فِتۡنَةٞ فَلَا تَكۡفُرۡۖ فَيَتَعَلَّمُونَ مِنۡهُمَا مَا يُفَرِّقُونَ بِهِۦ بَيۡنَ ٱلۡمَرۡءِ وَزَوۡجِهِۦۚ وَمَا هُم بِضَآرِّينَ بِهِۦ مِنۡ أَحَدٍ إِلَّا بِإِذۡنِ ٱللَّهِۚ وَيَتَعَلَّمُونَ مَا يَضُرُّهُمۡ وَلَا يَنفَعُهُمۡۚ وَلَقَدۡ عَلِمُواْ لَمَنِ ٱشۡتَرَىٰهُ مَا لَهُۥ فِي ٱلۡأٓخِرَةِ مِنۡ خَلَٰقٖۚ وَلَبِئۡسَ مَا شَرَوۡاْ بِهِۦٓ أَنفُسَهُمۡۚ لَوۡ كَانُواْ يَعۡلَمُونَ ١٠٢﴾ [البقرة: 102]

**Mo gbọ lẹnu ikan ninu awọn onimimọ pe ẹni ti o ba lero pe wọn sa sí oun, ki o mu ewe sidiru meje, lẹyin naa ko fi sinu peeli omi kan, ki o wa ka awọn surah iwasora (suuratul falaq ati Naas) ati suura : {Qul yaa ayyuhal kafirun}, ati ọrọ Ọlọhun ti ọla Rẹ ga pe : {Wa**

**maa unzila alal malakayni bibaabila haaruuta wa maaruuta}**[19]

Ati surah AL faatiha, kini ini alaafia ọrọ yii? Ati pe kini ẹniti o ro pe wọn ṣa si oun o ṣe? Ẹ se anfaani fún wa Ọlọhun naa a ṣe yin ni anfaani.

Èsì: Ko si iye meji pe dajudaju idán nbẹ ati pe apakan rẹ alupayida ni, o si maa n sẹlẹ ti o si tun maa n lapa pẹlu iyọnda Ọlọhun Alágbára ti O gbọnngbọn, gẹgẹ bi Ọlọhun ti mimọ n bẹ fún Un ti ọla Rẹ sì tún ga ṣe sọ nipa awọn opidan pe: Wọ́n sì tẹ̀lé ohun tí àwọn èṣù àlùjànnú ń kà (fún wọn nínú idán) lásìkò ìjọba (Ànábì) Sulaemọ̄n. (Ànábì) Sulaemọ̄n kò sì ṣàì gbàgbọ́, ṣùgbọ́n àwọn èṣù àlùjànnú ni wọ́n ṣàì gbàgbọ́, tí wọ́n ń kọ́ àwọn ènìyàn ní idán. Àwa kò sì sọ (idán) kalẹ̀ fún àwọn mọlāika méjì náà. (Àmọ́ àwọn èṣù àlùjànnú wọ̀nyí) Hārūt àti Mọ̄rūt ní (ìlú)

[19] Sūratul Baqoroh, Ayah: 102. "

Bābil (ni wọ́n ń kọ́ àwọn ènìyàn nídán). Wọn kò sì níí kọ́ ẹnikẹ́ni O n túmọ̀ si

﴿وَٱتَّبَعُواْ مَا تَتۡلُواْ ٱلشَّيَٰطِينُ عَلَىٰ مُلۡكِ سُلَيۡمَٰنَۖ وَمَا كَفَرَ سُلَيۡمَٰنُ وَلَٰكِنَّ ٱلشَّيَٰطِينَ كَفَرُواْ يُعَلِّمُونَ ٱلنَّاسَ ٱلسِّحۡرَ وَمَآ أُنزِلَ عَلَى ٱلۡمَلَكَيۡنِ بِبَابِلَ هَٰرُوتَ وَمَٰرُوتَۚ وَمَا يُعَلِّمَانِ مِنۡ أَحَدٍ حَتَّىٰ يَقُولَآ إِنَّمَا نَحۡنُ فِتۡنَةٞ فَلَا تَكۡفُرۡ﴾ [البقرة: 102]

: **Àwọn malaika mejeeji àyàfi kí wọ́n wí pé**: "**Àdánwò ni wá**. **Nítorí náà**, **má di kèfèrí**." **Wọ́n sì ń kẹ́kọ̀ọ́ ohun tí wọn yóò fi ṣòpínyà láàrin ọmọnìyàn àti ẹnì kejì rẹ̀ lọ́dọ̀ àwọn àlùjànnú méjèèjì**. – **Wọn kò sì lè kó ìnira bá ẹnikẹ́ni àyàfi pẹ̀lú ìyọ̀nda Allāhu**[20]

Nitori naa idán jẹ ohun ti o maa n ni ilapa ṣugbọn pẹlu iyọnda Ọlọhun eleyii ti O ti kọ akọsilẹ rẹ mọ ayé ni, nígbà tí o ṣe wipe ko si ohunkohun ti ń bẹ ayafi pẹlu idajọ ati

[20] Sūratul Baqoroh, Ayah: 102. "

kadara Ọlọhun ti mimọ n bẹ fún Un ti ọla Rẹ sì tún ga, ṣugbọn idan yii ni iwosan ati oogun, o si ti ṣẹlẹ sí Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ti Ọlọhun sì là á kuro níbẹ̀, ti O si tun ko o yọ nibi aburu rẹ, wọn sì ri ohun ti opidan ṣe, wọn sì mú un wọn si ba a jẹ, Ọlọhun si wo Anabi rẹ san kuro nibi idan naa (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a). Gẹgẹ bẹẹ naa ni ti wọn ba ri nnkan ti opidan ba ṣe bii tita awọn owu ni koko tabi dide awọn èsó mọ ara wọn tabi ohun miran, a maa ba a jẹ́; nítorí pé ninu iṣesi awọn opidan ni ki wọn o maa ta ọ̀dá sinu kókó, wọn yíò waa ti i pa fun àwọn erongba aburu wọn. Ohun ti wọn gbero a maa wa si imusẹ pẹlu iyọnda Ọlọhun, nigba miran a si maa bajẹ, ati pe Oluwa wa ti mimọ n bẹ fún Un ti ọla Rẹ sì tún ga julọ jẹ Olukapa lori gbogbo nnkan, ati pe nígbà míràn wọn maa n ṣe iwosan idan (asasi) pẹlu kika Alukurani, yálà pẹlu ki ẹniti wọn sàsí ka a fúnra rẹ ti laakaye rẹ ba lalaafia, tabi ki ẹlomiran ka a fun un, ti yio sí ta ọda si igbaaya rẹ tabi sibi ẹya kan ninu awọn ẹya ara rẹ, yio si ka fún un; Sūratul Faatihah ati Aayatul Kursiyy,

ati kul uwaLlahu ahad, ati kul a‘ūdhu kìíní-kejì, ati awọn aaya idan ti a ti mọ ninu Suratul A’raf ati Suratu Yuunus, ati Suratu Tọọhaa, ati pe ninu Suratul A‘rāf ni ọrọ Ọlọrun ti ọla Rẹ ga to sọ pe: A sì fi ìmísí ránṣẹ́ sí (Ànábì) Mūsā pé:

﴿۞ وَأَوْحَيْنَآ إِلَىٰ مُوسَىٰٓ أَنْ أَلْقِ عَصَاكَ ۖ فَإِذَا هِىَ تَلْقَفُ مَا يَأْفِكُونَ ﴿١١٧﴾ فَوَقَعَ ٱلْحَقُّ وَبَطَلَ مَا كَانُوا۟ يَعْمَلُونَ ﴿١١٨﴾ فَغُلِبُوا۟ هُنَالِكَ وَٱنقَلَبُوا۟ صَٰغِرِينَ ﴿١١٩﴾﴾ [الأعراف: 117-119]

“**Ju ọ̀pá rẹ sílẹ̀**.” **Nígbà náà, ó sì ń gbé ohun tí wọ́n ti pa níró kalẹ̀ mì kálókáló. Nítorí náà, òdodo dé. Ohun tí wọ́n ń ṣe níṣẹ́ sì bàjẹ́. Nítorí náà, A borí wọn níbẹ̀ yẹn. Wọ́n sì darí wálé ní ẹni yẹpẹrẹ**[21]

Ninu Suratu Yuunus ni ọrọ Ọba tí mimọ n bẹ fún Un ti o sọ pe: Fir ‘aon wi pe: “Ẹ lọ mu gbogbo awọn onimọ nipa

[21] Suuratul-a'raaf, aayah: 117-119.

idan pipa wa fun mi. Nigba ti awọn opidan si de, (Anabi) Musa sọ fun wọn pe

﴿وَقَالَ فِرۡعَوۡنُ ٱئۡتُونِي بِكُلِّ سَٰحِرٍ عَلِيمٖ ٧٩ فَلَمَّا جَآءَ ٱلسَّحَرَةُ قَالَ لَهُم مُّوسَىٰٓ أَلۡقُواْ مَآ أَنتُم مُّلۡقُونَ ٨٠ فَلَمَّآ أَلۡقَوۡاْ قَالَ مُوسَىٰ مَا جِئۡتُم بِهِ ٱلسِّحۡرُۖ إِنَّ ٱللَّهَ سَيُبۡطِلُهُۥٓ إِنَّ ٱللَّهَ لَا يُصۡلِحُ عَمَلَ ٱلۡمُفۡسِدِينَ ٨١ وَيُحِقُّ ٱللَّهُ ٱلۡحَقَّ بِكَلِمَٰتِهِۦ وَلَوۡ كَرِهَ ٱلۡمُجۡرِمُونَ ٨٢﴾ [يونس: 79-82]

: "**Ẹ ju ohun ti ẹ maa ju silẹ**. **Nigba ti wọn ju u silẹ**, (**Anabi**) **Musa sọ pe**: "**Idan ni ohun ti ẹ mu wa**. **Dajudaju Allahu si maa ba a jẹ**. **Dajudaju Allahu ko si nii ṣatunṣe iṣẹ awọn obilẹjẹ**. **Allahu si maa mu ododo ṣẹ pẹlu awọn ọrọ Rẹ**, **awọn ẹlẹṣẹ ibaa korira rẹ**"[22]

Ninu suuratu Tọọhaa ni gbolohun Ọba tí mimọ n bẹ fún Un ti o sọ pe: (Awọn opidan) wi pe: "Musa, iwọ ni o maa kọkọ ju (ọpa silẹ ni) tabi awa ni a oo kọkọ ju u silẹ.

[22] suuratu Yuunus, aaya: 79 – 82

(Musa) sọ pe: “Ẹ ju (tiyin) silẹ (na).” Nigba naa ni awọn okun wọn ati ọpa wọn ba n yira pada loju rẹ nipasẹ idan wọn, bi ẹni pe dajudaju wọn n sare. (Anabi) Musa si pa ẹru inu ọkan rẹ mọra. A sọ pe:

﴿قَالُواْ يَٰمُوسَىٰٓ إِمَّآ أَن تُلۡقِيَ وَإِمَّآ أَن نَّكُونَ أَوَّلَ مَنۡ أَلۡقَىٰ ٦٥ قَالَ بَلۡ أَلۡقُواْۖ فَإِذَا حِبَالُهُمۡ وَعِصِيُّهُمۡ يُخَيَّلُ إِلَيۡهِ مِن سِحۡرِهِمۡ أَنَّهَا تَسۡعَىٰ ٦٦ فَأَوۡجَسَ فِي نَفۡسِهِۦ خِيفَةٗ مُّوسَىٰ ٦٧ قُلۡنَا لَا تَخَفۡ إِنَّكَ أَنتَ ٱلۡأَعۡلَىٰ ٦٨ وَأَلۡقِ مَا فِي يَمِينِكَ تَلۡقَفۡ مَا صَنَعُوٓاْۖ إِنَّمَا صَنَعُواْ كَيۡدُ سَٰحِرٖۖ وَلَا يُفۡلِحُ ٱلسَّاحِرُ حَيۡثُ أَتَىٰ ٦٩﴾ [طه: 65-69]

"**Ma ṣe paya. Dajudaju iwọ, iwọ lo maa leke. Ju ohun ti n bẹ ni ọwọ ọtun rẹ silẹ. O si maa gbe ohun ti wọn ṣe kalẹ mi kalo. Dajudaju ohun ti wọn ṣe kalẹ, ete opidan ni. Opidan ko si nii jere ni ibikibi ti o ba de**"[23]

[23] suuratu Tọọhaa, aaya: 65 – 69

Yio si tun ka suurat {**kul yā ayyuhal kaafiruun**} de ipari re, ati suuratu {**kul uwa Llāhu ’ahad**} ati suuratu {**kul ’a ‘ūdhu bi robbil falaq**} ati suuratu {**kul ’a ‘ūdhu bi robbin nāsi**}. Ati pe èyí tí o dara julọ ni ki o paara suuratu ikhlaas ati suuratul falaq ati suuratun naas ni ẹẹmẹtamẹta, lẹyin naa ki o ṣe adura iwosan fun un: “Allāhumma robba an-Nās ’az'hib al-ba’s wash’fi Anta ash-Shāfi lā shifāha illā shifāhuka shifāhan lā yugādiru saqoman”, yoo paara eleyii lẹẹmẹta. Gẹgẹ bẹẹ naa ni yíò máa ke ruqyah fún un pẹlu gbolohun rẹ pe: “Bismillāh arqīka min kulli shay’in yu’dhīka wa min sharri kulli nafsin ao ‘aynin hāsidin Allāhu yashfīka bismiLlāhi arqīka”, yoo si paara rẹ lẹẹmẹta, wọn yíò si ṣe adura iwosan ati alaafia fun un, ti o ba sọ nibi ruqyah rẹ pe: “’U ‘īdhuka bi kalmāti Llāhi at-Tāmmāti min sharri mā khọlakọ”, ti o si paara rẹ lẹẹmẹta, ìyẹn naa dáa.

Gbogbo eleyii wa ninu awọn oogun ti o ṣe anfaani, ti o ba ka rukiya ati adura yii si inu omi, ti ẹni ti wọn sa si sì mu ninu rẹ ti o si fi iyoku wẹ, eleyii o maa bẹ ninu awọn okunfa iwosan ati alaafia pẹlu aṣẹ Ọlọhun, ti o ba tun fi ewe sidiru tútù meje sinu omi lẹyin ti o ba ti gun un tan, eleyii naa yíò maa bẹ ninu awọn okunfa iwosan. Wọn si ti dan èyí wo lọpọlọpọ igba ti Ọlọhun si fi anfaani si i, a si ti ṣe é fún ọpọlọpọ awọn eniyan ti Olọhun si fi iyẹn ṣe wọn ni anfaani, nitori naa oogun yii wulo, o si ṣe anfaani fun awọn ti wọn sa si, gẹgẹ bẹẹ naa ni oogun yii a maa ṣiṣẹ fun ẹniti wọn o jẹ ki o le ba iyawo rẹ ṣe lọkọ-laya (latara asasi); nitoripe wọn a maa se ẹlomiran pa kuro lọdọ iyawo rẹ ti ko sì nii ni ìkápá lati ba a ni Ibalopọ lọkọ-laya, ṣùgbọ́n ti o ba ti lo rukiya yii ati adura yii, yio ṣe e ni anfaani pẹlu iyọnda Ọlọhun, yala o kà á fun ara rẹ ni tabi ẹlomiran ka a fun un  tabi o ka a sinu omi, lẹyin naa o waa mu un ti o si fi iyoku wẹ, pẹlu iyọnda Ọlọhun, gbogbo eléyìí yíò ṣe anfaani fun ẹniti wọn sà sí, ati ẹniti wọn o jẹ ki o le ba iyawo rẹ ṣe lọkọ-laya (latara asasi). Awọn eleyii

wa ninu awọn okunfa ni, ṣugbọn Ọlọhun ti mimọ n bẹ fún Un ti ọla Rẹ sì tún ga julọ nikan ni Oluwosan, Oun si ni Olukapa lori gbogbo nnkan, ọwọ Rẹ ni oogun ati aiṣan wa, gbogbo nnkan patapata ni o si n bẹ pẹlu idajọ ati kadara Rẹ, ati pe o ni àlàáfíà (ẹgbawa) lati ọdọ ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - pe dajudaju o sọ bayii pe : (Ọlọhun ko sọ aisan kankan kalẹ ayafi ki O sọ iwosan kan kalẹ fún un, ẹnití o mọ ọn mọ ọn, ẹnití ko sì mọ ọn ko mọ ọn.

Eléyìí jẹ ọla lati ọdọ Rẹ mimọ n bẹ fún Un ọla Rẹ sì tún ga pẹlu, Ọlọhun si ni Afiniṣe kongẹ Afinimọna lọ sí oju ọna to tọ.

## Alaye ododo nipa wiwọle alujannu si ara ọmọniyan ati esi ọrọ fun ẹniti o ba tako iyẹn [28]

Gbogbo ẹyin ti Ọlọhun ni, ikẹ ati ọla ko lọ maa ba ojiṣẹ Ọlọhun ati awọn araale rẹ ati awọn saabe rẹ ati ẹniti o ba mọna pẹlu imọna rẹ.

Lẹyin naa, apakan awọn iwe iroyin abẹle ati awọn to yatọ sí wọn ti ṣe àgbéjáde ninu osu shaaban ninu ọdun yii, ọdun 1407 hijira, awọn ọrọ ti o wá ni ṣoki ati eyiti o gun nipa ohun ti o waye nipa kikede ọkan ninu awọn alujannu- eléyìí ti o ko si awọn Musulumi lobinrin kan lára ni Riyadh- gbigba isilaamu rẹ lọdọ mi lẹyin igba ti o ti kede rẹ lọdọ Abdullah ibnu Musharrof al'Umariy ti n gbe ni Riyadh, lẹyin ti ẹnití a darukọ yii (Abdullah ibnu Musharrof) ti ka nkan si ẹnití nkan mu lara, ti o si tun ba alujannu naa sọrọ, ti o si ran an leti nipa Ọlọhun, o si ṣe waasi fun un, o si tun fun un ni iro wipe dajudaju eewọ ni abosi ṣíṣe, ati pe ẹṣẹ nla ni, o si pe e sinu isilaamu nígbà tí alujannu sọ fun un pe keferi ẹlẹsin Búdà ni oun, o si pe

e ki o jade kuro lara rẹ, alujannu yii sì yọnu pẹlu ipepe naa, o si Kede gbigba Isilaamu rẹ lọdọ Abdullah ibnu Musharrof ti a darukọ ṣíwájú yẹn. Lẹyin naa Abdullah ti a darukọ yẹn ati awọn eeyan obinrin naa wa ṣojukokoro lati mu ọmọbinrin naa wa si ọdọ mi kí nle gbọ kikede gbigba Isilaamu alujannu naa, wọn waa wa si ọdọ mi, mo wa bi i leere nipa awọn idi ti o fi wọle si i lara, o si sọ awọn okunfa naa, o wa sọrọ pẹlu ahọn ọmọbinrin naa, ṣùgbọ́n ọrọ ọkunrin ni, kii ṣe ọrọ obinrin. Ọmọbìnrin naa wa nibi aga ti o wa ni ẹgbẹ mi, ti ọmọ-iya rẹ l'ọkunrin ati ọmọ-iya rẹ lóbìnrin ati Abdullah ibnu Musharrof ti a sọ yẹn ati awọn àgbààgbà kan si n jẹri si i ti wọn si n gbọ ọrọ alujannu naa. O si ti kede Isilaamu rẹ sita kedere, o si sọ pe oun jẹ ọmọ ilu India ti oun si n ṣe ẹsin Búdà. Mo waa ṣe iṣiti fun un, mo si pa a laṣẹ pẹlu ipaya Ọlọhun, ati pe ki o jade kuro ninu ọmọbinrin yii ki o si jina sí ṣiṣe abosi rẹ, o si jẹ ipe mi síbi ìyẹn, o si sọ pe: Mo yọnu pẹlu ẹsin Isilaamu, mo si sọ àsọtẹ́lẹ̀ fun un lati pe awọn ijọ rẹ sinu Isilaamu lẹyin ti Ọlọhun ti fi ọna Isilaamu mọ ọn, o si ṣe

ileri daradara, o si fi ọmọbinrin naa silẹ, igbẹyin ọrọ ti o si sọ ni pe: "As-salaamu alaykum". Lẹ́yìn naa ni ọmọbinrin yii waa sọrọ pẹlu ahọn rẹ gangan, ara sì tù ú. Lẹyin naa o pada wa si ọdọ mi lẹyin oṣu kan tabi jubẹẹlọ pẹlu awọn ọmọ-iya rẹ ọkunrin méjì ati ọmọ-iya ìyá rẹ ati ọmọ-iya rẹ l'obinrin, o si fun mi niro wipe oun wa daadaa, ati pe ko pada wa ba oun mọ, ọpẹ ni fun Ọlọhun, mo wa bi i leere nipa ohun ti o maa n nímọ̀lára rẹ nígbà tí o n bẹ pẹlu rẹ, o si dahun pe oun maa n nímọ̀lára awọn irori buruku ti o yapa si ofin Sharia, ọkan oun si maa n fa si ẹsin Búdà ati kika awọn ìwé ti wọn ṣe nípa rẹ. Lẹyin igba ti Ọlọhun la a kuro nibẹ, awọn irori wọnyi waa kuro lori rẹ, o si pada si iṣesi rẹ ipilẹ ti o jìnnà si gbogbo awọn irori kirori wọnyi. Ati pe o de etigbọọ mi nipa ọlọlajulọ Shaykh Aliyy Attontoowiy wipe o tako iru iṣẹlẹ alamọri yii, o si sọ pé ẹtanjẹ ati irọ lasan ni, ati pe o ṣeeṣe ki o jẹ ọrọ ti wọn ti ka silẹ pẹlu ọmọbinrin naa, ti kii ṣe wipe oun ni o sọ ọ. Ati pe mo ti beere fún kaseẹti ti o ka ọrọ rẹ sí ti mo sí mọ amọdaju nkan ti o sọ lati ibẹ, mọ wa ṣe eemọ

lọpọlọpọ nipa nǹkan ti o sọ pe o ṣeeṣe ki wọn ka ọ̀rọ̀ naa silẹ, pẹlu wipe mo beere oríṣiríṣi ibeere lọwọ alujannu naa ti o si n dahun, eleyi nbẹ ninu awọn aṣiṣe to burú púpọ̀ ati ṣíṣe ibajẹ ni ẹtọ, nibi ọrọ rẹ bakanna, o tun lero ninu ọrọ rẹ wipe gbigba Isilaamu alujannu yii lọwọ eniyan jẹ ohun ti o tako ọrọ Ọlọhun Ọba Aleke ọla nibi itan Anabi Sulaiman: (Ki o si tami ni ọrẹ ọla kan ti ko nii tọ si ẹlòmíràn lẹyin mi )(29) Ko wa si iyemeji wipe eléyìí jẹ aṣiṣe lati ọdọ rẹ, ki Ọlọhun fi ọna mọ ọn, ati agbọye ti ko dáa; nitori naa ko si ninu gbigba Isilaamu alujannu lọwọ ọmọniyan ohun ti o yapa si adua Anabi Sulaiman. Ọpọlọpọ ninu awọn alujannu ni o gba Isilaamu lọwọ Anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a).

Ọlọhun ti se alaye iyẹn ninu suuratul Ah'kọọf ati suuratul Jinn, o si f'ẹsẹ rinlẹ ninu sọhiihu Bukhari ati sọhiihu Muslim ninu hadīth Abu hurayra - ki Ọlọhun yọnu si i - lati ọdọ Anabi - kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - wipe o sọ pé: (Dajudaju Shaetọn yọ si mi, ni o ba kọlù mi

lati le ja irun mi, Ọlọhun sí mu mi kapa rẹ ti mo si fun un ni ọrun, mo si ti wa gbero lati de e mọ opo kan tító tí ẹ o fi jí, ti ẹ o sì máa wo o, mo waa ranti ọrọ ọmọ-iya mi Sulaiman - ki ọla Ọlọhun máa bá a – pe: (Irẹ Ọlọhun Ọba mi, forijin mi , ki o si ta mí lọrẹ ọla kan ti ko nii tọ si ẹlòmíràn lẹyin mi) (30) (Ọlọrun si da a pada ni ẹniyẹpẹrẹ) Eléyìí ni gbolohun Imaamu Bukhaari, ti Imaamu Muslim ni: Dájúdájú alaburu kan ninu awọn alujannu n gbéjà ko mi ni òru àná láti já irun mi, Ọlọhun si mu mi kapa rẹ, ni mo ba fun un lọrun, mo si ti gbero lati so ó mọ́ ẹgbẹ opo kan ninu awọn opo mọsalasi titi ti ẹ o fi jí ti gbogbo yin o si maa wo o lapapọ, lẹyin naa mo waa ranti ọrọ ọmọ-iya mi Sulaiman: (Irẹ Ọlọhun Ọba mi, forijin mi , ki o si ta mí lọrẹ ọla kan ti ko nii tọ si ẹlòmíràn lẹyin mi) (31) (Ọlọrun si da a pada ni ẹniyẹpẹrẹ) Imaamu Nasaai naa gba ẹgbawa lori majẹmu Imaamu Bukhaari lati ọdọ iya nla wa Aishat - ki Ọlọhun yọnu si i- wipe Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun lọ maa ba a- n kirun, ni Shaetọn ba wa ba a, Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun

máa bá a - wa gba a mu, o si da a mọlẹ, o si tun fun un lọrun, ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe: (títí tí mo fi ri itọ ahọn rẹ lori ọwọ mi, ti kii baa ṣe tori adua anọbi Sulaiman ni, ko ba di ẹni ademọlẹ ti awọn eniyan yoo fi ri i). Imaamu Ahmad ati Abu Daawud ni wọn gba a wa lati ibi adiisi abu Saheed, o si wa nínú rẹ pé: (Mo wa na ọwọ mi, mi o si yẹ lẹniti n fún un lọrun títí tí mo fi ri itutu itọ ẹnu rẹ laarin ọmọnika mi mejeeji yii, atanpako ati èyí tí o tẹle e) Bukhaari gbe e jade nínú sọhiihu rẹ ni muhallaq ti wọn fi rinlẹ, ìdì kẹrin, ojúewé 487 ninu Al-fat'hu, láti ọ̀dọ̀ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- pé ó sọ pé: Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) fi mi ṣe alakoso lati maa ṣọ Zakaat oṣu Ramadan, ẹnikan wa ba mi, o wa bẹrẹ lati maa mu ninu ounjẹ naa, mo wa gba a mu, mo wa sọ pe: Mo fi Ọlọhun bura, maa lọ fi ejọ rẹ sun Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a). O sọ pe: Ẹni tí o ni bukaata ni mi, mo si ni awọn mọlẹbi ati bukaata ti o le koko, o ni: Mo wa fi i silẹ, nigba ti mo wa ji, ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wa sọ

pe : Irẹ Abu-Huraira, kini ẹniti o mu ni alẹ́ àná ṣe ? Mo wa sọ pe: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, o pariwo bukaata ti o tobi ati awọn mọlẹbi rẹ, mo wa ṣaanu rẹ, mo si fi i silẹ. O sọ pe: o ti parọ fun ọ, yoo si tun pada wa, mo wa pada mọ pe yoo pada wa nitori ọrọ ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) Mo wa ṣọ ọ, o wa pada lẹniti o fẹ mu ninu ounjẹ naa, mo wa gba a mu, mo wa sọ pe: maa lọ fi ejọ rẹ sun Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a), o sọ pe: fi mi silẹ, ẹniti o ni bukaata ni mi, mo si ni awọn mọlẹbi, mi o si nii pada wa mọ Mo wa ṣaanu rẹ, mo si fi i silẹ, nigba ti mo wa ji, ojiṣẹ Ọlọhun (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wa sọ fun mi pe: Irẹ Abu-Huraira, kini ẹniti o mu ni alẹ àná ṣe, mo wa sọ pe: irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, o pariwo bukaata ti o tobi ati awọn mọlẹbi rẹ, mo wa ṣaanu rẹ, mo si fi i silẹ. O wa sọ pe: ṣugbọn o, o ti parọ fun ọ, yoo si tun pada wa, mo wa tun un ṣọ ni ẹlẹẹkẹta, o tun pada wa lẹniti o wa mu ninu ounjẹ, mo wa gba a mu, mo wa sọ pe: maa lọ fi ẹjọ rẹ sun Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) eleyii wa jẹ ẹlẹẹkẹta ti o maa sọ pe o o ni pada wa mọ, ṣugbọn

o tun maa pada wa, o wa sọ pe: fi mi silẹ ki n kọ ọ ni awọn gbolohun kan ti yoo ṣe ọ ni anfaani, mo wa sọ pe: kini awọn gbolohun naa? O sọ pe: ti o ba ti fẹ lọ sibi ibusun rẹ, ki o maa ka aayatul-kur'siyy (**Allaahu Laa ilaaha illa uwal Hayyul Qoyyuum**) titi de ipaari aaya naa oluṣọ kan lati ọdọ Ọlọhun maa wa pẹ̀lú rẹ, eṣu kankan ko si nii sunmọ ọ titi ti waa fi ji, ni mo wa fi i silẹ, nígbà tí mo ji, ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ fun mi pe: Kini ẹni tí o mu ni alẹ́ àná ṣe? Mo sọ pe: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, o kọ mi ni àwọn gbólóhùn kan ti o lérò pe Ọlọhun yoo jẹ ki o ṣe mi ni àǹfààní, ni mo wa fi i silẹ, o sọ pe: Kini gbólóhùn naa? Mo sọ pé: O sọ fun mi pe: Ti o ba ti fẹ sun, ka aayatul kursiy lati ìbẹ̀rẹ̀ de opin {**Alloohu laa ilaaha illaa Uwal Hayyul Qayyuum**}, o wa sọ fun mi pe: Olùṣọ́ kan lati ọdọ Ọlọhun maa wa pẹ̀lú rẹ, eṣu kankan ko si nii sunmọ ọ titi ti waa fi ji, wọn si jẹ ẹni tí maa n ṣe ojúkòkòrò oore julọ, ni Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- wa sọ pé : Ṣùgbọ́n o ti pada sọ ootọ fun ọ ti o si jẹ onirọ. Njẹ o ti

ẹ mọ ẹniti o n ba sọrọ fun awọn ọjọ mẹtẹẹta yii irẹ Abu-Huraira? Mo wa sọ pe: rara oo, o wa sọ pe: eṣu ni yẹn.

Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) sọ ninu Hadiisi ti o ni alaafia, eleyii ti Bukhaari ati Muslim gba wa lati ọdọ Sofiyyah (Ki Ọlọhun ba wa yọnu si i) wipe Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) sọ pe: Dajudaju eṣu maa n rin ninu ara ọmọ anọbi Aadamọ ni rinrin bi ẹjẹ ṣe maa n rin ninu ara). Imam Ahmad gba a wa ninu Mus'nad, ìdì ẹlẹẹkẹrin, ojúewé 216, pẹlu Isnad ti o ni alaafia, wipe : Uthman ọmọ Abu-l-Aas (ki Ọlọhun ba wa yọnu si i), o sọ pe : irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, eṣu maa n di mi lọwọ lori irun mi ati ti mo ba n ka nǹkan, o sọ pe : Eṣu ni yẹn, wọn si maa n pe e ni Khanzab, ti o ba ti mọ ọn lara, ki o fi Ọlọhun wa iṣọ kuro lọdọ rẹ, ki o si fẹ atẹgun si ẹgbẹ osi rẹ lẹẹmẹta, o sọ pe : mo wa ṣe iyẹn, Ọlọhun ti O ni agbára, ti O ga si mu un kuro fun mi. Gẹgẹ bi o ti rinlẹ ninu awọn Hadiisi ti o ni alaafia lati ọdọ Anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wipe gbogbo eeyan patapata ni o ni alabarin ninu awọn

Malaaika ati alabarin ninu awọn eṣu titi ti o fi de ori Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a), ṣùgbọ́n Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga ran an lọwọ lori rẹ, ti o si ti gba Isilaamu, ko nii pa a laṣẹ nkankan ayafi ki o jẹ nkan daadaa. Tira Ọlọhun ati sunna ojiṣẹ Ọlọhun (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ati ifẹnuko al-umma n tọka si pe alijannu le ko si eeyan lara, ti yoo si mu un ṣubú lulẹ. Bawo ni ẹniti wọn n ṣe afiti imọ si ọdọ rẹ o ṣe maa tako iru nnkan bẹẹ laini imọ kankan nipa rẹ abi imọna Lati fi tẹle awọn kan ninu awọn aladadaalẹ, awọn ti wọn yapa awọn Ahlus-sunnah wal Jamaa'ah. Ọlọhun ni Ẹni tí a n wa iranlọwọ Rẹ, ko si ete ati agbara kankan ayafi lati ọdọ Ọlọhun. Maa si sọ fun ọ, iwọ oluka yii, nǹkan ti o ba rọrùn ninu ọrọ awọn onimimọ nipa iyẹn ti Ọlọhun ba fẹ. Alaye ọrọ awọn Olutu-tira Ọlọhun (ki Ọlọhun kẹ wọn) nibi ọrọ Rẹ (Ọba ti O ga julọ):

﴿ٱلَّذِينَ يَأۡكُلُونَ ٱلرِّبَوٰاْ لَا يَقُومُونَ إِلَّا كَمَا يَقُومُ ٱلَّذِي يَتَخَبَّطُهُ ٱلشَّيۡطَٰنُ مِنَ ٱلۡمَسِّۚ ٢٧٥﴾ [البقرة: 275]

"**Àwọn t'ó ń jẹ èlé kò níí dìde** (**nínú sàréè**) **àfi bí ẹni tí Èṣù fọwọ́ bà tí ń ta gẹ̀ẹ́gẹ̀ẹ́ yó ṣe dìde**"[24].

Abu Ja'far ọmọ Jareer (ki Ọlọhun ba wa kẹ ẹ) sọ ninu ìtumọ̀ ọrọ Rẹ (ti O ga julọ):

﴿ٱلَّذِينَ يَأۡكُلُونَ ٱلرِّبَوٰاْ لَا يَقُومُونَ إِلَّا كَمَا يَقُومُ ٱلَّذِي يَتَخَبَّطُهُ ٱلشَّيۡطَٰنُ مِنَ ٱلۡمَسِّۚ ٢٧٥﴾ [البقرة: 275]

:" **Àwọn t'ó ń jẹ èlé kò níí dìde** (**nínú sàréè**) **àfi bí ẹni tí Èṣù fọwọ́ bà tí ń ta gẹ̀ẹ́gẹ̀ẹ́ yó ṣe dìde**"[25]

Ọrọ rẹ ni pe: Ìtumọ̀ iyẹn ni pe eṣu maa da ọpọlọ rẹ ru nile aye, oun ni yoo fun un lọrun, ti yoo si mu un ṣubú lulẹ) {latara gbigba a mu}, ìtumọ̀ rẹ ni pe: latara yiya-were.

---

[24] Sūratul Baqoroh, Ayah: 275. "

[25] Sūratul Baqoroh, Ayah: 275. "

Al-Bagọwiy (Ki Ọlọhun ba wa kẹ ẹ) sọ nibi alaye aayah ti a sọ yii pe:

﴿وَأَحَلَّ ٱللَّهُ ٱلۡبَيۡعَ ٢٧٥﴾ [البقرة: 275]

"**Wọn kò níí dìde** (**nínú sàréè**) **àfi bí ẹni tí Èṣù fọwọ́ bà tí ń ta gẹ̀ẹ́gẹ̀ẹ́ yó ṣe dìde**"[26]

Iyẹn ni pe : Yiya-wèrè. Wọn maa n sọ pé : Mussar-Rọjul, oun ni Mam'suus, ti o ba ti ya were. O pari.

Ibnu Katheer (ki Ọlọhun ba wa kẹ ẹ) sọ nibi alaye aayah ti a darukọ naa pe :

﴿وَحَرَّمَ ٱلرِّبَوٰاْ ٢٧٥﴾ [البقرة: 275]

---

26 Sūratul Baqoroh, Ayah: 275. "

**"Àwọn t'ó ń jẹ èlé kò níí dìde (nínú sàréè) àfi bí ẹni tí Èṣù fọwọ́ bà tí ń ta gẹ̀ẹ́gẹ̀ẹ́ yó ṣe dìde"**[27]

Iyẹn ni pe : wọn ko nii dide lati inu sàréè wọn ni ọjọ igbende ayafi gẹgẹ bi oniwarapa ṣe maa n dìde nígbà tí warapa ba gbe e ti eṣu si fi ọwọ ba a, ìyẹn ni pe yoo dide ni idide kan ti ọkan kọ. Ibnu Abbaas (ki Ọlọhun ba wa yọnu si i) si sọ pe : (Ẹniti ti o n jẹ riba, wọn o gbe e dide ni ọjọ igbende ni igbe dide ẹniti o ti ya weere, ti wọn maa fun un lọrun), Ibn Abii Haatim lo gba a wa, o sọ ọ, o si tun gba a wa.

Lati ọdọ Aof ọmọ Maaliki, ati Saheed ọmọ Jubayr, ati As-Suddiy, ati Robee'h ọmọ Anas, ati Qotaadah, ati Muqootil ọmọ hayyaan, ni ohun ti o jọ irun nnkan bẹẹ, ohun ti a gba lero ninu ọrọ rẹ (ki Ọlọhun ba wa kẹ ẹ) ti pari.

---

[27] Sūratul Baqoroh, Ayah: 275.

Qur'tubi (ki Ọlọhun ba wa kẹ ẹ) sọ ninu alaye rẹ lori ọrọ Rẹ (ti O ga julọ) :

﴿قَالُوٓاْ إِنَّمَا ٱلۡبَيۡعُ مِثۡلُ ٱلرِّبَوٰاْۗ وَأَحَلَّ ٱللَّهُ ٱلۡبَيۡعَ وَحَرَّمَ ٱلرِّبَوٰاْۚ ٢٧٥﴾ [البقرة: 275]

"**Àwọn t'ó ń jẹ èlé kò níí dìde** (**nínú sàréè**) **àfi bí ẹni tí Èṣù fọwọ́ bà tí ń ta gẹ̀ẹ́gẹ̀ẹ́ yó ṣe dìde**"[28]

Ẹri n bẹ ninu aayah naa lori ibajẹ àtakò ẹni ti n tako pe alujannu le mu èèyàn ṣubú lulẹ, ti o wa lero pe àdámọ́ ni o n fa a, ti o tun gba pe eṣu ko lee ya eeyan ni wèèrè. O pari. Ọrọ awọn olutumọ Kuraani lori itumọ yii pọ, ẹniti o ba fẹ ẹ, yoo ri i.

Sheikhul Islam, Ibnu Taymiyyah, sọ ninu tira rẹ: “Iidọọhud Dilaalati fii umuumir Risaalati lis sakọlaen” ti o wa ninu “Majmuuhul Fataawa” ìdì 19, ojúewé 9 dé 65, o sọ lẹ́yìn ọ̀rọ̀ to ṣáájú pé: Fun idi eleyii, awọn ikọ kan ninu awọn Mu'tazilah, gẹgẹ bii Al-Jubbaa’iy, ati Abubakr

[28] Sūratul Baqoroh, Ayah: 275.

Ar-rooziy, ati awọn ti o yatọ si wọn, wọ́n tako ki alujannu ko si ara ẹni ti o ṣubú lulẹ, àmọ́ wọn gba pe alijannu n bẹ; tori pé ihan eleyii ko si ninu nǹkan ti a gba wa láti ọ̀dọ̀ ojiṣẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a) gẹ́gẹ́ bii íhàn eleyii, bi o tilẹ jẹ pe wọn ṣe aṣiṣe lori eleyii naa. Fun idi eleyii ni Ash'ariy ṣe sọ nibi awọn ọrọ Ahlus Sunna Wal jamaa'ah wipe wọn maa n sọ pe:

﴿فَمَن جَآءَهُۥ مَوۡعِظَةٞ مِّن رَّبِّهِۦ فَٱنتَهَىٰ فَلَهُۥ مَا سَلَفَ وَأَمۡرُهُۥٓ إِلَى ٱللَّهِۖ وَمَنۡ عَادَ فَأُوْلَٰٓئِكَ أَصۡحَٰبُ ٱلنَّارِۖ هُمۡ فِيهَا خَٰلِدُونَ ٢٧٥﴾ [البقرة: 275]

"**Alijannu maa n wọ ara ẹniti wọn fi ọwọ ba gẹgẹ bi Ọlọhun ṣe sọ pe: Àwọn t’ó ń jẹ èlé kò níí dìde (nínú sàréè) àfi bí ẹni tí Èṣù fọwọ́ bà tí ń ta gẹ̀ẹ́gẹ̀ẹ́ yó ṣe dìde**"[29]

29 Sūratul Baqoroh, Ayah: 275.

Abdullaah ọmọ Ahmad ọmọ Hanbal sọ pe, mo sọ fun baba mi pe: awọn eeyan kan gba pe alijannu o kii n ko si ara ẹni tí ó ṣubú lulẹ. O wa sọ pe: Irẹ ọmọ mi, wọn n parọ ni, o maa n gba ori ahọ́n rẹ sọ̀rọ̀, a ti ṣàlàyé eleyii ni ààyè rẹ̀. O (ki Ọlọhun kẹ ẹ) tun sọ bakannaa ninu ìdì 24 ninu fataawa ni ojúewé 276-277 pe: Bibẹ alijannu fi ẹsẹ rinlẹ ninu tira Ọlọhun ati sunnah ojiṣẹ Rẹ, ati apanupọ awọn ẹni iṣaaju ati awọn adarí wọn. Bakannaa ni pe ki Alijannu wọ ara eeyan fi ẹsẹ rinlẹ pẹlu ifẹnuko awọn aṣiwaju Ah'lus-sunnah wal Jamaa'ah, Ọlọhun (ti ọla Rẹ ga) sọ pe:

﴿فَأُوْلَٰٓئِكَ أَصۡحَٰبُ ٱلنَّارِۖ هُمۡ فِيهَا خَٰلِدُونَ٢٧٥﴾ [البقرة: 275]

"**Àwọn t'ó ń jẹ èlé kò níí dìde** (**nínú sàréè**) **àfi bí ẹni tí Èṣù fọwọ́ bà tí ń ta gẹ̀ẹ́gẹ̀ẹ́ yó ṣe dìde**.[30]

[30] Sūratul Baqoroh, Ayah : 275.

O wa ninu Saheeh lati ọdọ Anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) - : Dajudaju eṣu maa n rin ninu ara ọmọ anọbi Aadamọ ni rinrin bi ẹjẹ ṣe maa n rin ninu ara).

Abdullaah ọmọ Ahmad ọmọ Hanbal sọ pe, mo sọ fun baba mi pe : awọn eeyan kan gba pe alijannu o kii n ko si ara ẹni tí o ṣubú lulẹ. O wa sọ pe : Irẹ ọmọ mi, wọn n parọ ni, o maa n gba ori ahọ́n rẹ sọ̀rọ̀, Nǹkan ti o sọ yii nǹkan ti o gbajúmò ni, eeyan maa n ṣubú lulẹ ti yoo si maa sọ nǹkan ti wọn o mọ ìtumọ̀ rẹ, wọn a maa na an gan ni nina ti o ṣe pe ti wọn ba na rakunmi ni iru rẹ yoo lapa lara rẹ, ṣùgbọ́n ẹni tí o ṣubú lulẹ yii ko nii mọ, koda ko tun nii mọ nǹkan ti o n sọ, ẹni ti alujannu ko si lara le maa wọ ẹni tí ko ko si lara

O tun le maa wọ ìtẹ́ ti o fi jókòó, ti yoo maa yi àwọn irinṣẹ pada, ti wọn a maa gbe e lati aaye kan bọ si òmíràn, àwọn nǹkan mii yàtọ̀ si ìyẹn maa n ṣẹlẹ̀, ti o ṣe pe ẹni tí ó bá ri i, yoo mọ daju pe ẹni ti n gba ẹnu eeyan naa sọ̀rọ̀ to n mi àwọn ara yii, ìran kan ni ti kii ṣe ọmọniyan.

Ko si ẹni kankan ninu awọn aṣiwaju Mùsùlùmí ti ko gba pe alijannu le ko si ẹniti wọn fi ọwọ ba lara. Ẹniti ko ba gba nnkan yii, ti o si sọ pe ofin n pa irọ, onitọun ti parọ mọ ofin, ko si si ninu awọn ẹri ofin ẹsin ti o tako ìyẹn. O pari.

Imaam Ibnul Qayyim- ki Ọlọhun kẹ ẹ- sọ ninu tira rẹ "Zaadul ma'haad fii hadyi khaeril ibaad", ìdì kẹrin, ojúewé 66 de 69, pe : Wiwo lulẹ méjì ni o wa : Ikan wa latara àwọn ẹ̀mí burúkú ti n bẹ lori ilẹ, ikan naa wa latara àwọn iropapọ inu ara mẹrin ti ko dara, ẹlẹẹkeji yii ni àwọn dokita n sọ̀rọ̀ nipa okunfa rẹ ati ìwòsàn rẹ̀. Ṣé ẹ wa ri wiwo lulẹ ti àwọn ẹ̀mí burúkú yii, àwọn agbaagba dókítà ati awọn oni làákàyè ninu wọn ko tako o, wọn si gba pe iwosan rẹ n bẹ nibi pipade àwọn ẹ̀mí gidi ti o wa lókè pẹ̀lú àwọn ẹ̀mí burúkú yẹn, wọn maa wa da a pada, wọn si maa ba iṣẹ wọn jẹ, Buk'raat naa sọ bẹẹ ninu awọn iwe rẹ kan, o sọ ìwòsàn wiwo lulẹ naa, o sọ pé : Eleyii maa wúlò fun wiwo lulẹ ti okunfa rẹ jẹ

Awọn idapapọ inú ara mẹrin naa, àmọ́ wiwo lulẹ ti o jẹ ti àwọn ẹ̀mí burúkú, iwosan yii ko wulo fun un

Ẹẹ waa ri awọn alaimọkan ninu awọn dokita ati awọn ẹniilẹ inu wọn, ati awọn ẹni yẹpẹrẹ inu wọn, ati ẹniti o ni adisọkan wipe ọla n bẹ nibi imaa yii ọrọ Ọlọhun pada, irufẹ awọn yẹn ni wọn máa n tako wiwo lulẹ (wárápá) to nii ṣe pẹlu awọn ẹmi (ẹmi àìrí), wọn o si ki n fi rinlẹ pe dajudaju o maa n lapa ni ara ẹniti o wo subu (ẹnití wárápá gbé  ko wa si nǹkankan ti n bẹ pẹlú wọn ayaafi aimọkan, bi bẹ́ẹ̀ ba kọ ni kò sí nǹkankan ninu imọ iṣegun ti o kọdi iyẹn, ati pe imọlara ati bibẹ n jẹrii sí i,  ati pe didari ọrọ wọn yẹn lọ síbi bibori apakan awọn akhlāt (àwọn iropapọ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí ń bẹ nínú ara) ootọ ni nibi apakan awọn ipin rẹ ko kii n ṣe nibi gbogbo ẹ. Titi ti o fi sọ pe : Àwọn Kèfèrí ninu awọn dokita wa de, ti wọn ko si fi nǹkankan rinlẹ afi wíwo lulẹ (wárápá) to nii ṣe pẹlu akhlāt (àwọn iropapọ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí ń bẹ nínú ara) nìkan, ẹniti laakaye ba wa fun un ati imọ nipa awọn ẹmi yii ati

awọn ilapa wọn, yíò rẹrin latara aimọkan awọn wọnyi ati lilẹ awọn laakaye wọn. Ati pe ìwòsàn iru iran yii o maa wáyé pẹlu nǹkan meji kan : Ikan ni abala ẹniti o wo ṣubú (ẹnití wárápá gbé), ìkan lati ọdọ oluwosan, eyiti ti o jẹ ti abala ẹniti o wo ṣubú (ẹnití wárápá gbé) maa wáyé pẹlu ìró ẹmi ara rẹ ni agbara, ati idokujọ òdodo si ọdọ ẹniti O ṣeda awọn ẹmi yii, ati iwasọra to ni alaafia to ṣe pe ọkan ati ahọn papọ lori rẹ. Dajudaju iru iran eyi ijanilogun ni, ati pe jagunjagun o le ri ọta rẹ̀ pa (ko le ri ẹsan gba lara ọta rẹ) pẹlu ohun ija afi pẹlu nǹkan meji kan : Ki ohun ija fúnra rẹ jẹ nǹkan tó ní alaafia daada, ki apá naa si ni agbara, gbogbo ìgbà ti a ba ti ṣafẹku ọkan ninu mejeeji, ohun ija o lee ṣe anfaani nìyẹn, bawo ni yio ṣe waa ri ti a ba ṣe afẹku mejeeji

Lapapọ, ọkan naa o tun jẹ nǹkan ti o pasofo nibi imọ Ọlọhun ni ọkansoso ati igbarale ati ipaya ati idojukọ, ti ko si nii si ohun ija kankan fun un.

Ẹlẹẹkeji lati abala oluwosan, pẹlu pe ki awọn àlámọ̀rí meji yii wa lara rẹ, koda ó ń bẹ ninu awọn oluwosan ẹnití o kan maa sọ pe : (Jáde lara rẹ), tabi ko sọ pe : (Bismillahi), tabi ko sọ pe : (Laa haola wa laa kuwwata illaa billahi), ati pe Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- jẹ ẹniti o maa n sọ pe : (Jade, iwọ ọta Ọlọhun, emi ni ojiṣẹ Ọlọhun). Mo foju ganni Sheikh wa ti o ranṣe si ẹniti alujannu wa lara re (ti o wo subu) ẹniti yíò ba emi to wa lara rẹ sọrọ, ti o wa nsọ pe : Sheikh wa sọ pe ki o jade ; tori pe dajudaju ẹni yìí ko tọ fun ẹ, ẹniti o wo ṣubu yẹn (ti wárápá gbé) si taji, o si ṣeeṣe ko jẹ pe oun fúnra rẹ lo ba a ṣọrọ, ó si le jẹ pe ẹmi naa jẹ alagidi nitori naa yio mu un jade pẹlu nina, ti ẹniti o wo ṣubu (ti wárápá gbé) ó si taji ti ko si nii mọ inira kankan. Ati pe awa ati awọn miran yatọ si wa naa ti fi oju ri iyẹn lara rẹ ni àìmọye ìgbà, titi ti o fi sọ pe : Ni akotan, iru iran yii ninu wiwo lulẹ (wárápá) ati iwosan rẹ, kò sí ẹniti o le tako o afi ẹniti ipin rẹ kere ninu imọ ati laakaye. Ati pe pipọ ninu jijẹ gaba awọn ẹmi burúkú lori awọn to ni i máa n waye latara kikere ẹsin

wọn ati ipasofo awọn ọkan wọn ati awọn ahọn wọn kuro nibi awọn ogidi iranti ati awọn gbolohun iwasọra ati iwaabo to jẹ ti Anọbi ati ti igbagbọ, latara bẹẹ, ẹmi burúkú naa o waa pade ọmọnìyàn ni ẹniti ti ko ni ohun ija, koda o le wa ni ihoho ni eleyi o ba lapa lara rẹ. Nǹkan ti a gba lero ninu ọrọ rẹ - ki Ọlọhun kẹ ẹ - ti pari.

Ati pe pẹlu nǹkan ti a darukọ ninu awọn ẹri sharia ati ipanupọ awọn onimimọ ninu awọn ahlu sunnah wal jamaaha lori rirọrun wiwọle alujannu sára ọmọnìyàn, yio han sí awọn oluka pe irọ ni ọrọ ẹniti o ba tako iyẹn ati asise ọlọla julọ Sheikh Tọntọọwiy nibi titako rẹ fun nǹkan yẹn.

Ati pe o ti ṣe àdéhùn nibi ọrọ rẹ lati ṣeri pada sibi ododo nígbà tí wọn ba tọ ọ sọna sibẹ, o wa ṣeeṣe fun un ko ṣeri pada lọ sibi eyi to tọna lẹyin to ba ka nǹkan ti a sọ, a bẹ Ọlọhun imọna ati ìfiṣe kongẹ fun wa ati fun un. Ati pe ninu nǹkan ti a sọ bákannáà wọn yíò mọ pe dajudaju nǹkan ti iwe iroyin nadwah gbe jade ninu onka

rẹ to jade ni 14/10/1407 A.H ni ojúewé kẹjọ, láti ọ̀dọ̀ dokita Muhammad i'rfaan pe dajudaju gbolohun "junoon" “yiya weere” ti pamọ ninu iwe atunmọ ede to jẹ ti imọ iṣegun, ati èrò rẹ wipe wiwọle alujannu sara ọmọnìyàn ati isọrọ rẹ lati ori ahọn rẹ jẹ asigbọye imọ ti o dájú. Gbogbo iyẹn ibajẹ ni to jẹyọ latara kikere imọ nipa awọn alamọri ofin sharia ati pẹlu nǹkan ti awọn onimimọ fi lelẹ ninu awọn ahlus sunnah wal jamaha, ti alamọri yii ba wa pamọ si ọpọlọpọ ninu awọn oniṣegun, ìyẹn o ki nṣe ẹri lori aisi rẹ, bi ko ṣe pe iyẹn da lori aimọkan wọn to tobi nipa nǹkan ti ẹniti o yato si wọn mọ ninu awọn onimimọ ti a mọ pẹlu ootọ ati ifọkantan ati imọ amọdaju pẹlu alamọri ẹsin. Amọ sa oun ni ifi ẹnu ko awọn ahlu sunnah wal jamaha, gẹgẹbi Sheikh Al islam ibn taimiyah naa ṣe gba a wa lati ọdọ gbogbo onimimọ, wọn sì tun gba a wa lati ọdọ Abul Hasan Al-’ash’ariy wipe o gba iyẹn wa lati ọdọ awọn ahlu sunnah wal jamaha. O tun gba a wa bákannáà lati ọdọ Abul Hasan Al-Ash’ariy,

agba onimimọ Abu Abdulahi Muhammad bn Abdulahi Ash-shibliy Alhanafiy to ku ni ọdun 799 A.H ninu.

Iwe rẹ : (Aakaamul marjaan fii goroohibil akhbaar wa ahkaamil jaan) ni ori kọkanlelaadọta ninu iwe rẹ ti a darukọ.

O si ti ṣaaju ninu ọrọ Ibnul Qoyyim, ki Ọlọhun kẹ ẹ, pe dajudaju awọn asaaju awọn onimọ iṣegun ati awọn oni laakaye ninu wọn máa nṣe afirinlẹ rẹ ti wọn o si ki n tako o, bikose pé awọn ti wọn tako ìyẹn ni awọn alaimọkan ninu awọn dokita ati awọn ẹni yẹpẹrẹ inu wọn ati awọn Kèfèrí inú wọn. Wa lọ mọ yẹn iwọ oluka, ki o si dirọ mọ nǹkan ti a sọ ni ododo, kí o si ma gba ẹtanjẹ pẹlu awọn alaimọkan ninu awọn onimọ iṣegun ati awọn to yatọ si wọn, ati pẹlu ẹniti o ba n ṣọrọ nipa alamọri yii laini imọ ati laini amọdaju, bikose pé o fi n tẹle awọn alaimọkan ninu awọn onimọ iṣegun ati apakan ninu awọn oni adadaalẹ ninu awọn muhtazilah ati awọn to yàtọ̀ si wọn, Ọlọhun ni ọba ti ao maa wa iranlọwọ Rẹ

## Akiyesi

Nǹkan ti a ti darukọ ninu awọn Hadiisi ti o ni alaafia lati ọdọ ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- ati ninu ọrọ awọn onimimọ da lori pe biba alujunnu sọrọ ati ṣíṣe waasi fun un ati ṣíṣe iranti fun un, ati pipe e sinu Isilaamu ati jijẹ ipe rẹ lọ si ibi iyẹn ko tako nǹkan ti ọrọ Ọlọhun ti ọla Rẹ ga da le lori nipa Anọbi Sulaiman, ki ikẹ ati igẹ Ọlọhun maa ba a, ninu Suratu Sọọd pe o sọ pe : Olúwa mi, forí jìn mí. Kí O sì ta mí ní ọrẹ ìjọba kan èyí tí kò níí tọ́ sí ẹnì kan kan mọ́ lẹ́yìn mi. Dájúdájú Ìwọ, Ìwọ ni Ọlọ́rẹ. Gẹgẹ bẹẹ naa ni pipa a laṣẹ pẹlu daada ati kikọ fún un kuro nibi iwa ibajẹ ati nina an nigbati o ba kọ lati jade, gbogbo iyẹn o tako ayah taa darukọ, bikose pé iyẹn jẹ dandan ni abala kikọdi ẹni ti o fẹ digbo lu èèyàn, ati ṣíṣe iranlọwọ fun ẹniti wọn bo si, ati pipase pẹlu daada ati kikọ kuro nibi iwa ibajẹ gẹgẹbi o se máa n ṣe ìyẹn pẹlu ọmọnìyàn. O ti ṣáájú ninu Hadiisi to ni alaafia pe dajudaju Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- so pe: O fun èṣù

lorun titi ti itọ rẹ fi san sori ọwọ rẹ abiyi (ki ikẹ ati ọla maa ba a), o wa sọ pe: (Ti o ba kii n ṣe ti adua ọmọ iya mi Anabi Sulaiman ko ba di ẹniti wọn yíò de mọlẹ titi ti awọn eeyan o fi ri i), Ninu ẹgbawa mii to jẹ ti Muslim ninu Hadiisi Abu Dardaah lati ọdọ Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- o sọ pe: (Dajudaju ọta Ọlọhun tii ṣe Ibliis mu ògúnná kan wa lati inu ina lati fi si oju mi, mo wa sọ pe: Mo fi Ọlọhun wa isọra kuro lọdọ rẹ lẹẹmẹta, lẹyin naa mọ wa sọ pe mo fi egbe Ọlọhun to pe ṣẹbi le ọ - ko sa sẹyin - lẹẹmẹta, lẹyin naa mo fẹ gba a mu, mo fi Ọlọhun bura, ti ko ba ki n ṣe tori adua ọmọ iya wa Anabi Sulaiman ni ko ba di ẹniti wọn yio de mọlẹ ti awọn ọmọde Madinah o maa fi í ṣere), Awọn Hadiisi to wa nipa itumọ yii pọ, ati pe báyìí naa ni ọrọ awọn onimimọ.

Mo n rankan pe ki tito ati itẹlọrun wa ninu nǹkan ti a sọ fun oluwa ododo, mo wa n bẹ Ọlọhun pẹlu awọn orukọ Rẹ to rẹwa ati pẹlu awọn iroyin Rẹ ti o ga ki O fi awa ati gbogbo Musulumi ṣe kongẹ agboye nibi ẹsin Rẹ, ati ifẹsẹ

rinlẹ lori rẹ, kí O sí tun ṣe idẹra le gbogbo wa lori síbi riri ododo nibi awọn ọrọ ati iṣẹ, ki O si sọ àwa ati gbogbo Musulumi kuro nibi sisọrọ nipa Rẹ laini imọ ati kuro nibi titako nǹkan ti imọ wa o tii de ibẹ, dajudaju Oun ni Alakoso iyẹn ati Olukapa lori rẹ.

Ki Ọlọhun ba wa ṣe ikẹ ati ọla Rẹ fun ẹru Rẹ ati ojiṣẹ Rẹ tii ṣe Anọbi wa Muhammad ati awọn araale rẹ ati awọn saabe rẹ ati gbogbo ẹni ti o fi daadaa tẹle e.

# Awọn akoonu

.ỌRỌ NIPA IDAJỌ IDAN ATI ṢÍṢE YẸ̀MÍWÒ .................... 1

Ọrọ isaaju .................................................... 3

..Ìdájọ́ idan ati ṣíṣe yẹmiwo, ati nkan ti o rọ mọ ọn [1] ..... 7

Asasi iyawo si ọkọ [16] .................................... 30

Ìdájọ́ bibeere nǹkan lọwọ awọn onidan ati awọn ti n pawọda [18] ........................................................ 35

Iwosan lọdọ dokita ibilẹ ti n lo alujannu ...................... 42

Iwosan ti ilana sharia fun idan [22] .............................. 45

Alaye ododo nipa wiwọle alujannu si ara ọmọniyan ati esi ọrọ fun ẹniti o ba tako iyẹn [28] .................................. 55

Akiyesi .......................................................... 79

Awọn akoonu.................................................... 82